# Kò Sì Mọ̀ Ọ́

Jeffersonville, Indiana USA

Ọjọ Kẹẹdogun, Oṣu Kejo, 1965

1 Ọ seun, Arakunrin Neville; ki Oluwa bukun fun ọ. Mo bọ sinu nkankan, tabi bẹẹkọ? Mo fẹ dupẹ gidigidi lọwọ Oluwa wipe O ran ọmọ Arakunrin Capp lọwọ. Ọ sẹlẹ wipe akoko kekere ti mo pada wa si Indiana niyi. Mo mọ wipe wọn ko gba eyi silẹ - emi ko ro bẹẹ. Emi ko ri ẹnikẹni nibẹ. Nitorinaa, mo pada wa lati lọ sọdẹ ọkẹrẹ. Mo si ro wipe Charlie yoo de si ọdọ mi - oun, Nellie, ati awọn ti wọn wa ni Kentucky, fun ọjọ kan tabi meji, lati sọdẹ ọkẹrẹ. O tẹ mi lọrun lati padanu ohunkohun, ani idaraya miiran, ki n si pada wa sibi ni aarin Oṣu Kẹjọ, ki n lọ sọdẹ ọkẹrẹ pẹlu Charlie, Banks, ati gbogbo wọn. O ti di àṣà fun mi. Nitorinaa, mo mu Joe…

2 Nigbati a wa nibi ni ijelo, gbogbo wa ṣaisan - iyipada lati agbegbe ti o gbona yẹn si eleyi ni, sibi agbegbe ti o tutu ti ẹ ni nibi yii. Mo mọ wipe ẹ ro wipe eyi ko tutu, ṣugbọn ẹyin ẹ wa si Arizona lẹẹkan. Iwọn gbibona naa jẹ mọkandinlaadọfa labẹ iji nigbati mo kuro ni owurọ ijelo; ni ọganjọ oru, ni oru, nigbati afẹfẹ tutu sọkalẹ lati ori awọn oke, o si jẹ iwọn mẹrindinlọgọrun sibẹ, se ẹ ri i. Ọganjọ oru niyẹn nigbati afẹfẹ tutu sọkalẹ. Ibẹyẹn dara ni igba otutu, ṣugbọn awọn akeekee ati alangba ni o wa fun ni akoko ooru - ki iṣe fun eniyan. Gbogbo awọn ẹranko paapaa maa n salọ si ori oke ni. Wọn ko lee farada a.

3 Mo ti jade lọ, mo n dan ibọn mi wo, mo si… Mo fẹ sọ fun yin nipa ọmọkunrin Capp. Mo ni… Mo nilati fun Joe ni ibọn naa, nitoriti o lee yan ibọn ju mi lọ. A n dan ibọn naa wo, mo si kan eekan kan mọlẹ ni aadọta ẹsẹ bata, mo sọ fun Joe… Joe wipe, "Baba mi, mo gbagbọ wipe mo leẹ se iyẹn." (Ọmọde naa ni ẹfọri. Mo ti n gbadura fun-un, o ni akọ iba. O pẹlu mi lọ sibi ti a ti n dan ibọn yiyan wo…) Ọpa ibọn kekere kan ti a fi si ara ibọn nla, ti o ba rekọja ibiti o yẹ ki agbara rẹ de ni ẹsẹ bata mẹẹdọgbọn, ti o si tuṇ se bẹẹ ni aadọta ẹsẹ bata, bi ẹni wipe ibọn kekere naa ni. Mo yan ibọn naa ni ẹsẹ bata mẹẹdọgbọn. Mo ni eekan meji tị ọ sẹku, mo si kan wọn mọlẹ, Joe si fi ibọn ré awọn eekan mejeeji! Emi ko ni eekan mọ, nitorinaa, mo fi amọ̀ ẹyẹle kan ti o ti fọ sibẹ - ohun ti awọn ọdẹ maa n yan ibọn si - ko fẹ ju bii idamẹrin inṣi kan - mo fi si aadọta ẹsẹ bata, o si ge e si meji. Oju temi ni a fị se iwọn awo oju ibọn naa - ọdun diẹ ni mo si fi ju oun lọ! O si wipe, "Njẹ ẹ mọ ohun ti ọ sẹlẹ? Mo nilati lọ sọ fun Billy wipe ki o pada lẹyin mi lati isisiyi lọ."

Nitorinaa, mo wipe, "O dara, jẹ ki n sọ nkankan fun ọ, jẹ ki a lọ fi iyẹn han Arakunrin Norman."

4 Mo ni, "Joe, ninu ifagagbaga kaakiri agbaye, (emi ko bikita ẹniti o lee jẹ) ko si ẹnikẹni… (Ni bayi, a ko kan eekan naa mọlẹ ni ẹ̀gbẹ́, a kan wọn mọlẹ taara ni. Bẹẹni eekan yẹn ko ju idamẹrin inṣi kan ati diẹ ni fifẹ, giga rẹ naa jẹ idamẹrin inṣi kan, o si ge e si meji lati aadọta ẹsẹ bata. Mo ni, "Ko si ẹnikẹni ni gbogbo aye ti o lee se daradara ju bẹyẹn lọ. Awọn ti o jẹ ọga ko leẹ se ju bẹẹ naa lọ, ṣugbọn iwọ ko lee yan ibọn ẹẹmẹta ti o dara ju tiwọn lọ. Awọn eekan naa ko tẹ̀ - o naro taara ninu iwe ti eekan naa gba kọja ni.)" Mo ni, "Ko si ẹniti o lee yan ibọn dara ju bẹyẹn lọ." Mo ro wipe ẹfọri rẹ fi i silẹ lẹsẹkẹsẹ.

Mo ni, "Oya, jẹ ki a lọ fi eyi han Arakunrin Norman," (ẹniti o n ṣiṣẹ fun ile-iṣẹ Field and Stream, ile-itaja Arakunrin Tony Stromei, nibiti wọn ti n ta awọn ohun elo idaraya.)

O ni, "Jẹ ki a kọkọ lọ si ọdọ Billy na." O ni, "Mo ṣaa fẹ sọ nkankan fun Bubby." (Nitootọ, ẹgbọn rẹ kọ se daradara to bẹyẹn ri.) O wa sọ pe, "A o kọkọ gba ibẹ lọ na."

5 Bi mọ se de ẹnu ilẹkun, Billy ṣì wà ninu aṣọ awọsun rẹ. O si wipe - a tete jade lọ nitori ooru maa n mu - nitorinaa, o wipe… Ẹrọ tẹlifoonu dun, mo si wipe… O wa wo mi bakan. Mo ni, "O lee jẹ alaisan kan ni o n pe;" Arakunrin Capps ni o n pe fun ọmọ rẹ, o wa ni iyara iṣẹ-abẹ ni akoko yẹn, o ni aisan kan ninu ifun rẹ. O ṣẹṣẹ sọ fun mi bayi ni, wipe ara ọmọ oun ti n ya kiakia.

Ṣe ẹ ri bi Ọlọrun tị se iṣẹ yẹn, ani ninu ohun ọmọkunrin kekere yẹn, Joe. Dipo ki a lọ si ile Arakunrin Norman… oun ki ba ti si nibẹ, ki a si tun wa, ki emi ati Arakunrin Capps pade. Emi ko sọ wipe adura wa ni o se e, ṣugbọn o jẹ nkankan fun oun wipe a pade bẹyẹn. Nitootọ, idi niyẹn… O nilati ni igbagbọ ninu ohun ti o n se. Igbagbọ rẹ̀ lati pè, Billy si sọ wipe oun n fi owo sinu ẹrọ tẹlifoonu naa, o si wipe, "Ipe yii nilati wa lati ọna jinjin réré," o ni oun fẹrẹ na to dọla marun owo ẹyọ, fun ipe iṣẹju mẹta pere.

Mo ro wipe New York ni o ti wá, tabi lati ọkan ninu awọn erekuṣu tabi nkankan, ṣugbọn ipe ẹnikan si ẹnikeji ni ọ se, lati ri Billy ba sọrọ taara dipo Loyce, se ẹ mọ, oye ti o si na a latị se bẹẹ niyẹn.

Ara ọmọ rẹ ti n ya bayi. Arakunrin Capps sọ wipe ireti kekere ni dokita fun oun wipe ọmọde naa yoo jade layọ lati ibi iṣẹ-abẹ naa, se ẹ ri i, a si dupẹ lọwọ Ọlọrun ni owurọ yii - inu mi dun pupọ fun-un.

6 Ilẹ fẹrẹ mọ ki a to wọle ni owurọ yii, bii wakati mẹta ni mo fi sun, o si rẹ mi gidigidi. Ṣugbọn nigbati ijọ … ti o to akoko lati wa si ile-ijọsin, mo sọkalẹ wa.

Bi Oluwa ba fẹ… Mo nilati lọ si Kentucky, bi mọ se sọ, lẹyinnaa, mo ni … mọ se ileri wipe emi yoo sọrọ ni ọjọ Sunday kan nigbati mo ba wa nihin, o si dara ki ṇ se e ni ọjọ Sunday ti o n bọ yii, nitori eyi to tẹle e, emi

yoo wa ni… mo nilati pada lọ, nitori mo tun n lọ si Canada. Nitorinaa, o dara ki ṇ se e ni ọjọ Sunday ti o n bọ, owurọ ọjọ Sunday ti o n bọ.

Arakunrin Neville sọ pe, "Iwọ kọ se jade lọ, ki o ki awọn eniyan, ki o si ba wọn sọrọ fun iṣẹju diẹ?"

Mo ni, "Arakunrin Neville, emi ko tilẹ tii ṣí Bibeli mi, kiki wipe mo…"

O ni, "O dara, jade lọ sọ nkankan fun wọn."

Arabinrin Neville, emi ko mọ bi o ti ṇ se e. O mọ bi a ti n rọ eniyan.

Ṣugbọn nigbati…

7 Emi kii ri aaye lati sọ eyi nigbati ibi yii ba kun, ti ero pọ, ati ohun gbogbo, ṣugbọn mo dupẹ lọwọ Ọlọrun fun oluṣọ-aguntan bii ti Arakunrin Orman Neville. Olootọ ni, o jẹ olootọ si iṣẹ naa gidigidi, ẹ ko si lee gbọ ki o maa kùn. Mo joko si ẹyin nibẹyẹn… Mo fi aabọ wakati baa sọrọ bi mọ se n gbadun Arakunrin Mann, nitorinaa, emi yoo baa sọrọ si i nipa iyẹn nigbati a ba de Colorado lọdun yii.

A n gbadun iwaasu rẹ̀; mo si ba Arakunrin Neville sọrọ daradara. Mo ni, "N ko tilẹ sọ ohunkohun fun awọn eniyan nipa oluṣọ-aguntan wa daradara." Mo ni, "se awọn eniyan ṇ se ọ daradara?"

O ni, "Ẹnikẹni ko leẹ se daradara ju bẹẹ lọ."

Mo si ni, "O dara, ohun ti inu mi dun si lati maa gbọ niyẹn." Nigbati oluṣọ-aguntan ba ni itẹlọrun, ti awọn eniyan naa ni itẹlọrun, yoo mu ki o jẹ ijọ ti o dara. Ọlọrun naa yoo si ni itẹlọrun. Lati ri i wipe wọn jọ ni itẹlọrun papọ, paapaa julọ ni ọjọ oni ti a n gbe iṣẹ-iranṣẹ iwaasu yii dani, mo ro wipe iyẹn fihan wipe iṣẹ-iranṣẹ iwaasu naa n tẹsiwaju pẹlu awọn eniyan ati pẹlu Ọlọrun, se ẹ ri i.

8 Mo dupẹ pupọ fun Arakunrin Orman Neville ati iyawo ati ẹbi rẹ ti o dara. Mo gbadura wipe ki Ọlọrun pa wọn mọ gẹgẹbi olootọ si Oun, ati si iṣẹ Rẹ. Ti o ba wu u, a fẹ ki a wa ninu agọ ijọsin yii nigbati Jesu Oluwa ba wa fun wa, lati mu wa lọ ninu igbasoke. A ni ireti wipe awa mejeeji yoo ti di arugbo, Arakunrin Neville, wipe a o fi ọwọ kọ ara wa, a o si duro sibẹ lori ọpa itiṣẹ wa, ki a maa gbiyanju lati duro sibẹ.

A o si pa wa lara da ni iṣẹju kan, ni iṣẹju aaya. A o bọ agọ ẹran-ara yii silẹ, a o si goke lọ, a o gba ẹbun ayeraye naa, a o si maa pariwo bi a̩ se n lọ ninu ofuurufu, wipe, "O digbooṣe, o digbooṣe, wakati adura didun"; a o goke lọ.

9 Mo gbọ nipa iwosan Arakunrin Coomer lati ọdọ Oluwa, a si dupẹ pupọ fun iyẹn. Ọpọ awọn nkan ni o wà! Nitorinaa, mo dupẹ pupọ lati wa nibi ni owurọ yii, mo si ro wipe dipo… Mo maa n wa sibi pẹlu akori ọrọ kan pato, mo si n sọrọ… Mo ro wipe emi yoo jade wa ni owurọ yii. Mo ni, "Arakunrin Neville, emi yoo maa fi suuru wo aago, boya n o jẹ ki awọn eniyan tete jade, ki n si ba yin sọrọ lati inu ọkan mi, fun iṣẹju diẹ; nipa awọn nkan ti a … a mọ wipe wọn ko gba ohun yii silẹ tabi ohunkohun, nitorinaa, a o ni idapọ nigbati o jẹ wipe awọn ọmọ-ijọ nikan ni o wa nibi, laarin ara wa." Nitorinaa, ẹ jẹ ki a gbadura.

10 Jesu ọwọn, a dupẹ lọwọ Rẹ fun anfaani ti a ni lati pejọ pọ sibi yii, bi mọ se wo ile-ijọsin yii ni kutukutu owurọ yii - lẹyin ti oru ti kọja - mo ronu nipa bi Ọ se duro ti i. Mo ronu nipa akurọ ti o wa nibi yii tẹlẹ, pẹlu awọn koriko nla ti o naro sibẹ, ni ibi ti pẹpẹ iwaasu yii wa. Gẹgẹbi ọmọdekunrin, mo duro sibẹ, Ọgbẹni Ingram sọ wipe a lee lo ilẹ naa fun iwọnba owo diẹ, ki a san owo diẹ silẹ, ko si si owo, bẹẹni ko si ohun ti a lee fi duro, a ko ni ohunkohun lati fi silẹ, ṣugbọn a ṣaa gbiyanju. Bi ọ se jẹ wipe ni igba yẹn, ẹkunrẹrẹ owo ilẹ naa le diẹ ni ẹgbẹrun meji dọla; ti a o si fi ogun ọdun san-an tan.

Ni bayi, Oluwa, wo o bayi. Nigbati o ṣẹṣẹ bẹrẹ, ti o wa ninu koto nibi yii, ti omi n da sinu rẹ; Ọ se ileri fun wa nipa Ọrọ naa, wipe: "Emi Oluwa ni o ti gbin-in, Emi yoo bu omi rin-in tọsan-toru, ki ẹnikẹni ma baa gba a lọwọ mi." Ni akoko kan yẹn naa, awọn eniyan wipe, "Laarin oṣu mẹfa, yoo di ibi ti a n gbe ọkọ si."

11 Ṣugbọn ẹgbẹẹgbẹrun awọn ọkan ni o ti ba Kristi pade nibi pẹpẹ nibi yii. Ile-ijọsin yii, nigbagbogbo ni ibi ti a ti ṇ se baptisiimu… A ti baptiisi awọn eniyan ni orukọ Jesu Oluwa, wọn n pe orukọ Rẹ, wọn n wẹ ẹ̀ṣẹ̀ wọn nu. Ọgọọgọrun awọn arọ, awọn ti a n da loro, awọn afọju, amukun, arọ, awọn ti jẹjẹrẹ ti jẹ, ni wọn ti rin lọ kuro nibi pẹpẹ yii - wọn wọle wa gẹgẹbi ẹniti o n ku lọ, awọn ọkunrin, obinrin, ọmọdekunrin, ọmọdẹbinrin, wọn si jade lọ lati gbe igbe-aye ọtun pẹlu ẹran-ara titun ni ara wọn, wọn si tun n rin; wọn kuro ninu kẹkẹ arọ wọn, ati ọpa itilẹ ati bẹẹ bẹẹ lọ. Ọlọrun o, iṣẹ-isin ọgbọn ọdun yii…

Baba, ranti owurọ ọjọ ti a fi ipilẹ ile yii lelẹ. O fun mi ni iran kan nibẹyẹn, o fi ibi yii han, o kun fun awọn eniyan, o jẹ ibi ti o rẹwa; mo mọ wipe iyẹn ko lee kuna. Nitorinaa, mo dupẹ lọwọ Rẹ fun gbogbo nkan wọnyi.

12 Ọpọlọpọ wọn ni o ti ja ija rere, wọn ti pari ere-ije wọn, wọn si ti pa igbagbọ mọ; wọn wa nibẹyẹn, wọn n

duro, wọn n simi bayi kuro ninu laalaa wọn, iṣẹ wọn si n tọ wọn lẹyin - wọn n duro de wakati ti ipe yoo dun, ki wọn si jade wa ninu iye titun - ara titun. Ọpọlọpọ wọn ni o ti di arugbo, ti wọn si n gbọn, awọn miiran jẹ ọdọ, agba ati bẹẹ bẹẹ lọ. Ṣugbọn a yin orukọ Rẹ fun gbogbo wọn.

A tun ti wa nibi yii, niwaju … awọn alaaye ati awọn oku. Mo gbadura wipe ki O ta ami-ororo si Ọrọ Rẹ ni owurọ yii. Emi ko mọ ohun kan ti mo lee sọ, ṣugbọn mo gbadura wipe ki O fun mi ni iyẹn, bi O ti maa ṇ se tẹlẹ, Oluwa. Bukun fun oluṣọ-aguntan wa, Arakunrin Neville; ati iyawo rẹ. Bukun fun awọn alabojuto, igbimọ awọn diakoni, ati gbogbo ọmọ-ijọ. Jẹ ki gbogbo wa gbe igbe-aye wa ni aye yii, wipe ki a lee ni iye ainipẹkun ni aye ti o n bọ.

Ran wa lọwọ ni owurọ yii lati gba itọsọna lati ọwọ Ẹmi ati Ọrọ naa, ki a lee pese ara wa silẹ bi a ọ se jade sita ni ẹnu ilẹkun ni owurọ yii, ki a pinnu ninu ọkan wa lati gbe igbe-aye ti o dara si i ju eyi ti a ti n gbe tẹlẹ lọ. A beere rẹ ni orukọ Jẹsu. Amin.

13 Mo ṣí Bibeli nibi yii, ọ sẹlẹ wipe ni iṣẹju melo kan sẹyin… Mo wa ni iwe Ifihan, ori kẹta, nitorinaa n o ka ibi yii, nipa iṣẹ ti a ran si ijọ Laodikea.

Mo fẹ̣ se ifilọ pẹlu (Arakunrin Neville ṣẹṣẹ n sọ fun mi ni) Arakunrin Parnell - mo ṣẹṣẹ wo isalẹ, mo si ri i ti o joko sibi yii - o ṇ se isọji kan lọwọ, ni eti Memphis nibi. Bi ẹnikẹni ninu yin ba mọ ibi ti ile itaja ounjẹ ipanu Wimpy wa tẹlẹ, ibẹ ni o pagọ si, o n gbiyanju lati ru awọn iti wọle, ati lati wo o boya a ri ẹnikẹni ti o ti sọnu ni ọna yẹn, eyiti a ti yan tẹlẹ si iye, wipe ki oun lee jere rẹ fun Kristi nipa iṣẹ-iriju oun. Yoo pari rẹ ni ọjọ Sunday nitori awọn isin ti a ṇ se ninu ile-ijọsin nibi yii, iyẹn fihan wipe olootọ ni arakunrin naa. A si fẹ ki ẹ mọ wipe isin naa yoo bẹrẹ ni alẹ ọjọ Monday lẹyin ọsẹ ti o n bọ, mo si mọ wipe gbogbo yin ni a fi tifẹtifẹ pe lati gbọ bi Arakunrin Parnelḷ se n mu iwaasu ifẹ Kristi wá.

14 Ni bayi, ẹ jẹ ki a ka lati inu iwe Ifihan, ori kẹta, apakan nibẹ, fun Bibeli kika, nitori ohun ti emi yoo sọ lee kuna, ṣugbọn ohun ti Oun sọ ko lee kuna. Emi ko mọ ibiti mo ti lee bẹrẹ, ohun ti mo leẹ se, tabi ibi ti mo lee lọ, ṣugbọn ẹ jẹ ki a ka igba ijọ Laodikea.

Ati si angẹli ijọ ni Laodikea, kọwe; Nkan wọnyi ni ẹniti ijẹ Amin wi, ẹlẹri olododo ati olootọ, olupilẹsẹ ẹda Ọlọrun.

Emi mọ iṣẹ rẹ, … iwọ ko gbona bẹẹni iwọ ko tutu: emi iba fẹ pe ki iwọ kuku tutu, tabi ki iwọ kuku gbona.

Njẹ nitoriti iwọ̣ se ilọwọọwọ, ti o ko si gbona, bẹẹni o ko tutu, emi yoo pọ ọ jade kuro ni ẹnu mi.

Nitoriti iwọ wipe, Emi ni ọrọ, emi si n pọ si i ni ọrọ, emi ko sị se alaini ohunkohun; ti iwọ ko si mọ pe, oṣi ni iwọ, … ati are, … ati afọju, … ati ẹni-ihooho:

Emi fun ọ ni imọran pe ki o ra wura lọwọ mi ti a ti da ninu ina, ki iwọ ki o lee di ọlọrọ; ati aṣọ funfun, ki iwọ ki o lee fi wọ ara rẹ, ati ki itiju ihooho rẹ ki o ma baa han; ki o si fi oogun kun oju rẹ, ki iwọ ki o lee riran.

Gbogbo awọn ti emi ba fẹ ni mo n ba wi, ti mo si n na: nitorinaa, ni itara, ki o si ronupiwada.

15 Njẹ ẹ mọ, nibikan ni ibẹyẹn bi mo ti n ka a - ti ẹ ba lee fun mi ni iṣẹju kan si i - mo ri ibikan ti o dun mọ mi, emi ko si mọ ibi ti o wa bayi. Oun niyi: “Ti iwọ ko si mọ, wipe ẹni oṣi ni iwọ, ati are, ati talaka, ati afọju, ati ẹni-ihooho.” Kai! Bi ijọ onị se ri niyẹn. Mo ro wipe igba ijọ ti a n sọrọ rẹ yii… Lootọ, ẹkọ nipa awọn igba ijọ yoo jade ninu iwe laipẹ yii. Ṣugbọn nitoriti o jẹ wipe igba ijọ Laodikea ni a n gbe inu rẹ̣, ẹ jẹ ki a wo ipo ti o wa.

Emi ko fẹ mu akori kankan tabi ohunkohun, nitoriti a ko … a kan n ba ara wa sọrọ ni, gẹgẹbi a o ti sọrọ lori ohunkohun ti Oluwa ba dari wa latị se. Ṣugbọn ohun kan ti yoo ran wa lọwọ ni.

Ẹ jẹ ki a ronu nipa igba ijọ Laodikea ati ipo rẹ loni. Bi ọ se ye mi si, emi ko ri ohun kan ti o ṇ se idiwọ fun bibọ Jesu Oluwa ni akoko yii, yatọ si imurasilẹ ijọ Rẹ. Mo ro wipe ọkan ninu awọn asọtẹlẹ niyẹn. 16:39

16 Ni ana, bi ạ se n bọ ninu ọkọ… Ọjọ meji ni a fi wa ọkọ lati Tucson de ibi yii, ẹgbẹrun maili meji, emi ati Billy. Nitorinaa, a… Iyẹn jẹ lai ru ofin ere sisa loju popo. A duro ni… Emi yoo joko nigbati oun ba n wa ọkọ… Mo jẹ … emi yoo di ẹ̀ṣẹ́ ọwọ mi bii ibọn ni ẹyin rẹ, pẹlu oolu. Ti mo ba ri i wipe o n sare, emi yoo wipe, “Duro na, ọmọ.” Ni bayi, a sọ fun wa wipe, “Ẹ fi ohun ti iṣe ti Kesari fun Kesari.”

A de ibi ni alẹ ana… Ọmọdebinrin kan sun gbalaja si oju titi, bii ọmọ ọdun mẹta; iya rẹ ti ku sinu koto kan. Ọmọkunrin kan ti o ti mu ọti yo, o n bọ lati ROTC, ọmọ ọdun mejidinlogun, o n wa ọkọ ni ọgọfa maili laarin wakati kan ni apa osi oju ọna naa … o pa a, mo si ro wipe oun naa n ku lọ pẹlu. Ẹ mọ ohun ti o jẹ. “Ẹ fi ohun ti iṣe ti Kesari fun Kesari.”

17 Awọn alaiṣẹ n ku. Ọmọdebinrin ọmọ ọdun mẹta kan padanu ẹmi rẹ, nitori ọmọ-ogun kan ti o mu ọti yo, ti

o n wa ọkọ ni ọgọfa maili ni wakati kan, ni ọna òdì loju titi. O gun oke, o si sare wa si isalẹ, o si pa gbogbo wọn nibẹ. Oun naa n ku lọ pẹlu, nitorinaa… Ẹ ri i, bi o tilẹ jẹ wipe awọn alaiṣẹ yẹn ṇ se…

Ọmọkunrin yẹn jẹbi ipaniyan, se ẹ ri i. Mo ro wipe ti a ba mu ẹnikan loju titi ti o n mu ọti, o yẹ ki wọn ran-an lọ si ẹwọn ọdun mẹwa fun ẹsun ipaniyan - ẹnikẹni yoowu ti o jẹ, nitori wọn, ẹnikẹni…

18 Oṣelu ko leẹ se wa ni rere kankan. O ti bajẹ. Èrò Ọlọrun lati ni ọba, ọba olododo, iyẹn ni o tọna. Ṣugbọn oṣelu kan n gbilẹ ni… O lee fi owo ra ohunkohun; irẹnijẹ, irọ pipa, ole jija, ati ohun gbogbo miiran. Bi mọ se sọ ni ọjọ Sunday melo kan sẹyin, "Ẹ wo ibiti ẹ wa." Ẹ wo o, kiki jibiti ni gbogbo rẹ. Ṣugbọn ọba olododo leẹ se ofin ti ara rẹ. O lee pa eniyan, ti o ba mọ oṣeluṇ se daradara, iwọ yoo bọ ninu rẹ. Ijọba tiwa-n-tiwa jẹ èrò ti o dara, ṣugbọn ko lee ṣiṣẹ. Gẹgẹbi ijọba Aparo-kan-ko-ga-ju-ọkan-lọ: wipe ki gbogbo eniyan ni gbogbo nkaṇ bakannaa. O dun lati gbọ leti, ṣugbọn ko lee ṣiṣẹ. Rara. Ọna Ọlọrun ni lati ni ọba kan, bii Dafidi, ni … ni o tọ́. Ọkan kan ni yoo wa, ti yoo duro lori… Gẹgẹbi olori kan laarin awọn pẹpẹyẹ, ati bẹẹ bẹẹ lọ. O ko lee mu meji tabi mẹta ninu wọn. Iwọ yoo ba gbogbo rẹ jẹ ni, iwọ yoo si mu oriṣiriṣi èrò wá. A ri i wipe ipo ti ọjọ oni wa, ti mura de bibọ Oluwa.

19 Nigbati emi ati Arakunrin Neville, ati awọn arakunrin ti o ku wọnyi, ti a n gbiyanju lati jẹ oluṣọ-aguntan fun agbo kan, mo ni nkankan lọkan mi bayi, eyiti a lee sọrọ nipa rẹ. Iyẹn ni… Mo gba lẹta kan ni ijelo lati ọdọ obinrin rere kan. Emi ko ri i gba; ọdọ ẹlomiran ni o gba wa. O si n bú mi gidigidi, tabi o n gbiyanju latị se bẹẹ. O ni, "Njẹ o tilẹ…̣ se ẹyin Ọkunrin Kristẹni Oniṣowo ko leẹ se nkankan lati da Arakunrin Branham duro ni?" o ni, "nitori o ti gbe iwe kan jade bayi, eyiti o pe ni Igba Ijọ Laodikea, yoo si tun gbe awọn miiran jade si i." O ni, "O kan n wo ẹkọ ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ palẹ ni." O ni, "Ni bayi, o tun ti sọ wipe ifedefọ kiị se ẹri akọkọ fun Ẹmi Mimọ." O ni, "Lẹyin iyẹn, o tun lodi si awọn obinrin oniwaasu." (Ẹni yii si jẹ obinrin oniwaasu!)

Awọn ọmọkunrin rẹ - lara awọn ọrẹ ti o dara ju ti mo ni ni aye ni wọn - wọn wa lara awọn ọrẹ ti o dara ju ti mo ni. O wa sọ pe…

20 Ọkunrin yii ati iyawo rẹ (emi pẹlu wọn jọ n jẹ ounjẹ owurọ) wọn ni, "Arakunrin Branham, wo nkan yii, kini o ro nipa rẹ?" o si mu lẹta kan jade.

Mo ni, "Ko buru, arabinrin, ko loye ni."

Awọn ọmọkunrin naa sọ fun mi wipe oniwaasu obinrin ni iya awọn, ati wipe ko gba iṣẹ-iranṣẹ iwaasu akoko yii. O sọ nibẹ… O sọ pe, o ni, "Awọn obinrin ko gbọdọ paṣẹ lori ọkunrin." O ni, "Febe nkọ ninu Bibeli, oluranlọwọ Pọọlu."

Dajudaju. Ontaja ni. Pọọlu sọ fun awọn eniyan…̣ se ẹ ro wipe Pọọlu yoo sọ pe, "Jẹ ki awọn obinrin dakẹ jẹẹ ninu ijọ," lai fi aaye gba wọn lati sọrọ, ki o si tun yipada, ki o wipe, "Ni bayi, Febe, oluranlọwọ mi ninu ihinrere, oun naa yoo waasu ni alẹ ọjọ melo kan." Eeṣe, yoo tako ọrọ ara rẹ, se ẹ ri i.

O ni, "Ju gbogbo rẹ lọ (mo gbagbọ wipe Esteri ni, ti o jẹ ọkan ninu awọn onidajọ ninu Bibeli) o ni obinrin kan jẹ onidajọ ninu Bibeli. Ṣe iyẹn kii ṣe aṣẹ lori ọkunrin…"

21 Oniṣowo kan ti a mu lara da ninu ijọ nibi yii laipẹ yii, o ni, … iyawo rẹ wipe, "Arakunrin Branham, iyẹn maa n ya mi lẹnu ni gbogbo igba."

Mo ni, "Eeṣe, arabinrin, bawo ni iyẹn ṣe lee ya ọ lẹnu?"

O ni, "Ko buru, obinrin onidajọ niyi."

Mo ni, "Oṣelu niyẹn, kii ṣe ijọ. Iyẹn ko ni nkankan ṣe pẹlu ijọ." Pọọlu wipe, "Jẹ ki wọn wa labẹ igbọran, gẹgẹbi ofin pẹlu ti sọ." Ofin ko lee fi obinrin ṣe alufaa, ko lee fi… Ẹ ko lee ri obinrin ti o jẹ olori alufaa; ẹ ko lee ri obinrin ti o jẹ alufaa - ko si ninu Bibeli. Ko si obinrin oniwaasu ninu Bibeli. Lootọ, awọn kan ninu wọn jẹ wolii obinrin ati bẹẹ bẹẹ lọ; Miriam ati awọn miiran, ati Ẹsteri, tabi ọkan ninu wọn jẹ onidajọ ni Israẹli. Igba miiran, wọn maa n jẹ ayaba lori wọn ati bẹẹ bẹẹ lọ, ọba ati ayaba. Nigbati ọba ba ku, ayaba nilati gba ipo rẹ titi ti wọn yoo fi yan ọba miiran, ati bẹẹ bẹẹ lọ.

22 Ni Tucson, Arizona, a ni obinrin kan nibẹ ti o jẹ onidajọ ni ilu yẹn. Idi niyẹn ti ilu naa fi bajẹ to bẹẹ. A si ni… Obinrin ko ni ohunkohun ṣe ninu oṣelu. Ko ni ohunkohun ṣe lati ni aṣẹ ninu ijọ. Aaye rẹ ni lati jẹ ayaba ni ile ọkunrin kan. Yatọ si iyẹn, ko ni nkankan. A si mọ wipe otitọ niyẹn. O ko lee ri… Mo mọ wipe iyẹn dabi ọrọ ara atijọ, ṣugbọn mo ni ojuṣe kan.

Mo mọ wipe lẹyin ti mo ba kuro ninu aye yii, awọn fanran ati awọn iwe naa yoo maa wa titi, ọpọlọpọ ẹyin ọmọ yoo si ri i ni ọjọ iwaju wipe otitọ niyi, nitoriti mo sọ ọ ni orukọ Oluwa.

23 Ni bayi, o n ya wa lẹnu bi obinrin rere - lati ipasẹ ọkọ rẹ ti o jẹ eniyan rere, o bi awọn ọmọ si aye, awọn ti

o jẹ wipe wọn wa lara awọn ọmọkunrin ti o dara ju ti mo tii ba pade ri, ọkunrin gidi ni wọn, ti mo tii ba pade ri - ni kiakia, ni kete ti wọn gbọ iṣẹ-iranṣẹ iwaasu yii, wọn gba a patapata. Nipa iyantẹlẹ nikan ni iyẹn fi lee ṣẹlẹ. Ọna kanṣoṣo ti o lee gba wa niyẹn.

Ni bayi, ibeere kan wa, mo n ronu wipe… Nigbati Oluwa n mu mi pada wa - “ko si mọ … iwọ ko mọ wipe iwọ wa ni ihooho, o jẹ ẹni oṣi, are, afọju, o ko si mọ ọ.”

24 Ki n to de ibẹyẹn, mo fẹ sọ ohun ti mo sọ ni ọjọ melo kan sẹyin nibi yii, ninu iwaasu, Ọlọrun Aye Yii. O ti fọ oju awọn eniyan tobẹẹ ti wọn n sin eṣu nibi iṣẹ-isin. ṣe gbogbo yin ni iyẹn ye - ṣe o ye gbogbo yin?

Ninu iwaasu kan yẹn naa, mo mu ọrọ kan jade wipe obinrin ti o n wọ aṣọ ìwọ̀kuwọ̀, a o ṣe idajọ rẹ nibi itẹ idajọ gẹgẹbi aṣẹwo. Iyẹn dabi ẹni wipe o ṣe ajeji.

Ẹ jẹ ki n ṣalaye nkankan fun yin.

25 Agbẹjọro kan wa ninu ilu, ọ̀dọ́ ni. Eniyan rere ni, nipa ti oṣelu… Mo lero wipe o n ṣe daradara ninu oṣelu rẹ; lẹyinnaa, o n ba ọmọbinrin kan rin, ẹniti o jẹ olokiki. Wọn fẹran ara wọn, wọn si ṣe igbeyawo. Wọn n lọ si gbogbo ibi ase ati awọn nkan nla-nla bẹẹ, wọn si jọ n mu ọti papọ. Nikẹyin, o … o ni ile ti o dara; o n gbe agbegbe ti o dara. Awọn eniyan fẹran rẹ, ṣugbọn o … awọn mejeeji ni o n mu ọti; iyawo n wọ ṣokoto penpe, o n ge irun rẹ, o n ṣe ara lọṣọ; o n ṣe ohun gbogbo gẹgẹbi arẹwa obinrin oniṣekuṣe - o n fi ara rẹ han sita.

Kii lọ si ile-ijọsin rara, ko si eyiti o n lọ ninu awọn mejeeji. Ẹnikan tun ko de itosi wọn, obinrin kan lati ijọ Onitẹbọmi tabi ijọ Eleto, oun ati ọkọ rẹ. Njẹ obinrin yii… (Ẹ jẹ ki a pe e ni Eleto, nitori ijọ Eleto gbagbọ ninu iwa mimọ ju ijọ Onitẹbọmi lọ - gbogbo wọn, yatọ si New Testament Baptist; wọn gbagbọ ninu iwa mimọ. Ṣugbọn ni ọpọ igba, awọn ijọ Onitẹbọmi ko gbagbọ ninu iwa mimọ rara, wọn ko gbagbọ ninu iru nkan bẹẹ. Ni bayi, ẹ jẹ ki a pe e ni ijọ Eleto nitoriti awọn gbagbọ ninu iwa mimọ.)

26 Obinrin ọmọ ijọ Eleto kan ṣẹṣẹ ko si ile ti o wa ni itosi obinrin yii ni titi kannaa. Ọkọ rẹ jẹ… Ẹ jẹ ki a sọ wipe o jẹ oluṣiro owo ni ile-iṣẹ kan. Obinrin ijọ Eleto yii wo obinrin keji yii, nigbati agbẹjọro yii ba lọ si irin-ajo … Johanu ni orukọ rẹ. Ki a sọ wipe Johanu ni orukọ rẹ. (Ni bayi, ẹ maṣe ro iyẹn; mo kan n lo orukọ arosọ lasan ni,) - Johanu ni orukọ rẹ. Obinrin yii si n ba Ralph jade. (Orukọ arosọ lasan niyẹn o - gbogbo rẹ, ki itan naa lee ye yin ni, ki ẹ lee ri ohun ti mo n sọ.)

Ohun ti o̩ sẹlẹ ni wipe nibi ase ọti amupara kan, Ralph tun di mọ ọ. Ara rẹ gbina jẹ, nitoriti o tun ni ifẹ Ralph, o ro bẹẹ. Lẹyin igba diẹ, Ralph n pade rẹ, o si lee purọ fun Johanu; yoo fi juujuu bo o loju, o si ro wipe oun jafafa, nitoriti o lee maa tẹle Ralph; bẹẹni Johanu ni ọkọ rẹ.

Obinrin yẹn ko tilẹ ni iwa rere kankan. Ko tilẹ ro nkankan nipa rẹ.

27 Ṣugbọn a tọ́ obinrin ijọ Eleto yii dagba ni ọna miiran. Oun tilẹ n lọ si ile-ijọsin; o si ro wipe obinrin yẹn buru pupọ. Yoo sọ fun ọkọ rẹ, nigbati o ba de, wipe, “Mo ri i ti ọkunrin yẹn wọle lọ ba a. Nigbati Johanu ba si lọ̩ se iṣẹ agbẹjọro nibikan, boya ni Filadelfia tabi ibomiran, o maa n gbe e jade ninu ọkọ rẹ, wọn yoo si jọ sun si eti bebe okun. Mo ri i ti wọn jọ wa si ile; wọn kii tilẹ fa aṣọ oju ferese wa si ilẹ nigbamiran, yoo maa fi ẹnu ko o ni ẹnu, wọn yoo si jọ maa ṣe ere ifẹ. Ah, ṣe nkan buburu ha kọ niyẹn,” o n sọ bẹẹ fun ọkọ rẹ. “Kai, aja igboro lasan ni obinrin yẹn.”

Otitọ ni. O buru ju aja igboro lọ, nitori adelebọ obinrin ni̩ se ẹ ri i. Obinrin eleyi, obinrin ọmọ ijọ Eleto yii ro wipe ohun ti o buru niyẹn. Kii lọ si ile-ijọsin.

28 Obinrin ijọ Eleto yii ki yoọ se iru nkan bẹyẹn. Rara. Obinrin oniwa rere ni oun. Ohun miiran niyi, kii fi ọwọ kan ọti, nitori ijọ Eleto … eyiti o pọ ju ninu awọn eto wọn ni o lodi si ọti mimu, ọti mimu. Nitorinaa, wọn ni eto kan ti o lodi si ọti mimu, awọn ara ijọ Eleto yẹn ko si lee gbe igbe-aye ti o ga ju ohun ti ijọ yẹn n kọ wọn lọ.

Ṣugbọn obinrin yii kannaa, obinrin ijọ Eleto yii yoo jade lọ ni ọwọ irọlẹ pẹlu ọkọ rẹ, o n wọ ṣokoto penpe ni ọjọ Sunday lẹyin ile-ẹkọ Ọjọ Isimi, o n ge irun rẹ, o n tọ́ ètè, o si n mu siga diẹ.

Ninu Ọrọ Ọlọrun, aṣẹwo ni awọn mejeeji. Eyi wa ni ihooho, o jẹ ẹni oṣi, are, afọju, ko si mọ ọ. Awọn mejeeji ni o jẹbi. Nitori ọkunrin ti o wo obinrin lati̩ se ifẹkufẹ si i ti ba ą se panṣaga tan ninu ọkan rẹ.

29 Ti obinrin yii… Ni bayi, o lee wipe, “Duro na, Ọgbẹni Branham. Mo fẹ ki o mọ wipe emi kii̩ se aṣẹwo!” Arabinrin mi, boya ti a ba mu ọ lọ siwaju Bibeli, ki o gbe ọwọ rẹ le e niwaju Ọlọrun, ki o si bura wipe o jẹ olootọ si ọkọ rẹ patapata. Ọkọ rẹ lo ni ara rẹ, ṣugbọn Ọlọrun lo ni ọkan rẹ. Ẹmi eṣu kan wa ti o n ta ami-ororo si ọ. Aijẹbẹẹ, a jẹ wipe mo lee fidi rẹ mulẹ fun ọ wipe were patapata gba a ni ọ.

Kini ibą sẹlẹ si iya-iya rẹ ti o ba jade si oju titi pẹlu ṣokoto penpe nidi? Wọn yoo fi si ile itọju awọn were ni - nitoriti o jade sita lai wọ aṣọ. Nkankan ņ se ọpọlọ rẹ. Ti o ba ri bẹẹ ni igba yẹn, bẹẹ naa ni o ri nisisiyi.

O wa sọ gbogbo aye di were. Gbogbo wọn ti di asinwin. Diẹdiẹ ni o n wọle, tobẹẹ ti awọn eniyan ko mọ ọ.

30 Ṣe aṣẹwo ni? Ki iṣe nipa ẹ̀jẹ́ ọkọ rẹ si ara rẹ, ṣugbọn niwaju Ọlọrun, o ni ẹmi aṣẹwo ninu rẹ, eyiti o n mu ki o wọ aṣọ bẹyẹn, o si wa ni igba ijọ Laodikea, ko si mọ wipe oun n ṣe iru nkan bẹyẹn. Obinrin alaimọkan naa ko mọ wipe Ọlọrun yoo ṣe idajọ oun gẹgẹbi aṣẹwo. Bi o ṣe ri niyẹn.

Ẹ lee lọ si ọdọ rẹ. Ẹ ko lee sọ fun-un. Ko si ọna lati sọ fun-un. Bibeli wipe, “Wọn wa ni ihooho, wọn ko si mọ ọ.”

Ti iwọ ba pe e ni aṣẹwo, yoo fi ọlọpa mu ọ ni; yoọ se bẹẹ. Emi kii sọrọ nipa ẹnikẹni. Ẹ̀ṣẹ̀ ni mo maa n sọrọ nipa rẹ. Emi kii sọ pe, “Ijọ bayi-bayi, Ọgbẹni Lagbaja, Ẹni-ọwọ Lakasegbe, o jẹ…” Rara, rara. Mo maa n sọ pe … ẹkọ iyẹn, gbogbo rẹ lapapọ… Emi kii darukọ ẹnikẹni. Kii ṣe ọrọ ẹnikẹni; ilana ti wọn wa labe rẹ ni, ilana aye ni.

31 Arakunrin George Wright ti o joko sibi yii - o ti di ọmọ ọdun marundinlọgọrin tabi mejidinlọgọrin, mo ro bẹẹ - kini o ro wipe ibạ sẹlẹ, ti o ba jade lọ ri Arabinrin Wright lọjọ kan, ki o si duro pẹlu ṣokoto penpe nidi? Iwọ ki ba ti … iwọ yoo jẹ ki wọn ti obinrin naa mọle ni. O ki ba ti fẹ ẹ laelae.

Ti ọdọmọkunrin kan ni igba yẹn yoo bạ se e, nkan kannaa ni ibạ sẹlẹ. Ti o ba jẹ ẹṣẹ, ti o si lodi ni igba yẹn, bakannaa ni bayi; ṣugbọn awọn eniyan ti dagba sinu isinwin.

32 Ẹ jẹ ki n sọ asọtẹlẹ nkankan fun yin ki o to wa si imuṣẹ. Gbogbo aye ti wa ni ipo isinwin, yoo si maa buru si i ni, titi ti gbogbo wọn yoo fi jẹ were; o si ti fẹrẹ ri bẹẹ bayi.

Njẹ ẹ lee ronu pe eniyan lee maa wa ọkọ loju titi lai tan ina, ọmọ ita kan, ọdọmọkunrin ti o yẹ ki o ṣẹṣẹ jade ile-iwe giga, ti o si pa ọpọlọpọ eniyan? Njẹ iyẹn ha da wọn lẹkun bi?

Ẹlomiran tun tẹle e, o n̦ se nkan kannaa̦ se ẹ lee ronu nipa ọdọmọkunrin kan ti o ro nipa ara rẹ … ti o ronu ohun rere si ara rẹ, ki iru ẹni bẹẹ jade sita, ki o si maa ṣe bi wọn ti n ṣe yẹn? Njẹ ẹ lee fi oju inu wo ọdọmọbinrin ti o ṣẹṣẹ n dagba bọ, arẹwa, pẹlu ara ti o dara, ati oju ti o rẹwa; ẹwa rẹ gan-an fihan wipe a ti wa ni igba ikẹyin. O ti lo gbogbo awọn nkan aye yii, awọn eroja aye yii, kii ṣe ẹwa iwa mimọ, pẹlu adun ninu ọkan rẹ. Mo ti ri awọn obinrin ri, wọn ko dun lati wo ni ode ara, ṣugbọn ti o ba ba wọn sọrọ lẹẹkan, ti o ba ba wọn sọrọ fun iṣẹju diẹ; wọn jẹ eniyan gidi; ohun ti o ko lee kuro ninu rẹ. Ẹ wo o, ẹwa ode jẹ ti eṣu; ti aye ni.

33 Ẹ wo awọn ọmọ Kaini, bi wọn ṣe lọ sinu rẹ. Nigbati awọn ọmọkunrin Ọlọrun ri awọn ọmọbinrin eniyan wipe wọn rẹwa, wọn mu aya fun ara wọn, Ọlọrun ko si dariji wọn.

Ẹ wo o, nigbati awọn ọmọbinrin Israẹli, pẹlu ọwọ wọn ti o le, ati irun wọn ti o tuka; nigbati awọn ọmọkunrin Ọlọrun wọnyẹn de ilẹ Moabu, ti wọn si ri awọn ẹlẹgẹ obinrin, pẹlu irun wọn ti o n dan, ati ọpọlọpọ ọda ni oju wọn - tabi kini ẹ n pe e - nigbati awọn ọmọkunrin Ọlọrun ri awọn arẹwa obinrin wọnyẹn, wolii eke kan sọ pe, “Ọkannaa ni gbogbo wa.” Wọn fẹ iyawo laarin wọn, Ọlọrun ko si dariji wọn; wọn ṣegbe ni aginju.

Gbogbo wọn ni o ku sibẹ, laini ireti, laini Ọlọrun, wọn si sọnu titi ainipẹkun, a da wọn lẹbi ayeraye, lootọ wọn ti ri oore Ọlọrun, lootọ wọn ti mu ninu isun naa ti kii gbẹ. Wọn mu lati inu okuta ti a lu. Wọn ti ri i ti ejo idẹ naa ṣe iṣẹ iyanu. Wọn jade lati abẹ baptisiimu Mose ninu okun. Wọn ti ri ọwọ Ọlọrun. Wọn ti jẹ ounjẹ awọn angẹli, wọn si ti ṣe gbogbo nkan wọnyẹn. Ṣugbọn wọn fẹ … wọn jẹ ki awọn obinrin mu wọn wọle, wọn si fẹ iyawo laarin wọn. Wọn ko ṣe panṣaga; wọn kan fẹ iyawo laarin wọn ni. Ọlọrun ko dari rẹ ji.

34 Igba keji ti yoo ṣẹlẹ niyẹn. A ti wa ni igba kẹta bayi: o si ni ẹtan ni akoko yii ju ti tẹlẹ lọ. Mo mọ wipe ọrọ ti o le niyẹn, mo si ti maa n ronu ni gbogbo ọna, wipe bawo ni iyẹn ṣe ri bẹẹ? Eeṣe ti mo fi n sọrọ lile si awọn eniyan? Ki lo fa a? Sibẹ, mọ se akiyesi wipe, ti kii ba iṣe Ọlọrun, ki yoo si ẹnikẹni; ko si obinrin kan ti yoo joko lati feti si mi. Ṣugbọn wọn tun n pada wa. Nitori ẹnikan wa ti o ni idakọro otitọ ninu ọkan rẹ, ti o mọ wipe otitọ niyẹn; laibikita, wọn mọ wipe otitọ ni.

Ẹ kiyesi ohun ti o ṣẹlẹ bayi. Mo mọ wipe o le.

35 O dabi igba ti dokita ba fun ọ ni oogun, ti o si kọ lati lo o, maṣe da dokita lẹbi, ti o ba ku. Eyi dabii oogun. Awọn eniyan ti wọn n sọ wipe mo korira obinrin nkọ. Ṣe ẹ ri i, ẹyin ẹ kiyesi bi awọn obinrin ṣe n huwa, emi yoo fi bi ijọ ṣe ri han yin. Iwa awọn obinrin ni Laodikea, ninu aye, ni ti ara - wọn wa ni ihooho, wọn jẹ ẹni oṣi, afọju ni wọn, wọn ko si mọ ọ.

Awọn eniyan, awọn obinrin aye … ijọ si ti wa ni ipo kannaa. Ẹ kiyesi i, ohun ti ara maa n ṣe apẹẹrẹ ti ẹmi ni gbogbo igba.

Lọjọ kan nibi itẹ idajọ…

36 Mo mọ wipe ko gbajumọ lati sọ bẹẹ; ti a ko ba si yan ẹnikan tẹlẹ lati sọ ọ, o dara ki o maṣe sọ ọ, nitori o n ṣe afarawe niyẹn; iwọ yoo si bọ sinu wahala.

Ẹ kiyesi i bayi, mo maa, o dabi ẹni wipe ni igbamiran, mo nilati la ẹnu obinrin, ki n si da oogun naa si ẹnu rẹ; lẹyinnaa, ki n tun fi ọwọ bo ẹnu rẹ, sibẹ, ṣe ni o n tu u jade ni gbogbo igba. Njẹ ti dokita ba ṣe bẹẹ si alaisan nkọ, a jẹ wipe alaisan naa ku nitoriti o kọ lati gbe oogun naa mi. Nibi itẹ idajọ, nigbati gbogbo nkan wọnyi bii gige irun, ati wiwọ ṣokoto penpe…

37 Mo n fi ipilẹ lelẹ ni o. Akoko ti sunmọ tosi nigbati ẹ o ri i ti nkankan yoo ṣẹlẹ, nigbati nkankan yoo ṣẹlẹ, gbogbo ipilẹ yii n fi ipilẹ lelẹ ni, fun iwaasu kukuru kan ti yoo mi gbogbo orilẹ-ede.

Mo ti n ba awọn obinrin wi: o ti wa nibi yii, ani ohun ti a fi lee sọ oju abẹ ni iko. Mo n gbiyanju lati sọ ohun ti o tọ fun wọn. Mo gbe ọwọ wa si ilẹ bi eleyi, ibi ti ẹnu wọn wa niyi; wọn yoo si tu u jade sita. Tani yoo wa da dokita lẹbi?

Kini ẹ o sọ ni ọjọ idajọ, nigbati awọn ohùn ti o kigbe lodi si i yoo tun dun pada loju awọn eniyan? Bawo ni wọn yoo ṣe bọ ninu rẹ?

38 Wọn yoo tu u jade laarin ọwọ rẹ. Ti o ba tun da diẹ si i, wọn yoo mi ori wọn, wọn yoo si pada sẹyin - wọn ki yoo gba a. Sibẹ, iwọ yoo tun pada wa, iwọ yoo si tun da a si wọn lẹnu. Tani o yẹ ki a bawi? Kii ṣe dokita, kii ṣe oogun, ṣugbọn iṣesi ẹni yẹn ni. Bẹẹ ni.

Yoo jẹ ọjọ buburu lọjọ kan, nigbati iran ẹlẹṣẹ ati panṣaga yii yoo duro niwaju Ọlọrun Olodumare.

39 Bi mo ṣe ri ọjọ ori mi ti o n lọ, ejika mi ti n yẹ, mo si mọ… Ọgbọn ọdun niyi lori pẹpẹ yii … bẹẹni, ọdun mẹtalelọgbọn lori papa iwaasu, ọjọ pipẹ niyẹn. Isin ọdun mẹtalelọgbọn niyẹn. Abamọ kanṣoṣo ni mo ni: wipe n ko ni ọgọrun ọdun o le mẹtalelọgbọn fun-un. Eyi ni anfaani kanṣoṣo ti mo ni, nigbati mo wa ninu ara kiku yii, lati waasu Ihinrere; ki Ọlọrun ran mi lọwọ lati jẹ olotitọ gidigidi si Ọrọ naa, ki n si sọ ọ bi O ṣe sọ ọ.

Kini o ṣẹlẹ si obinrin ijọ Onitẹbọmi yẹn; bawo ni o ṣe fẹ sọ fun-un? O wa ninu igba ijọ Laodikea.

40 Ẹ jẹ ki a mu obinrin ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ bayi. Ko yẹ ki o wọ ṣokoto penpe, tabi kun ete, tabi ki o ge irun rẹ, ṣugbọn oun naa tun wo obinrin ijọ Onitẹbọmi yẹn, wipe: “Wo o, obinrin yẹn n ṣe bayi-bayi.” Obinrin eleyi kii wọ ṣokoto penpe o, ṣugbọn o sọ pe … ṣugbọn oun ge irun rẹ. Bi o ba ṣe ga si i ninu Ọlọrun to, bẹẹni gbogbo awọn nkan wọnyẹn yoo jẹ ẹṣẹ si ọ to.

Nigbamiran ninu adura, o lee ronu igba ti Ẹmi Mimọ yoo gbe ọ lọ si ipele kan, gbogbo rẹ yoo jẹ rudurudu. Nigbati o ba wa sọkalẹ wa si isalẹ, yoo dabi ẹni wipe o … loju awọn eniyan, ìpátá ni ọ, o si tun jẹ oniyẹyẹ… Omugọ ni ọ, nitoriti o duro bii were atijọ kan, o si n ba awọn eniyan wi; ṣugbọn ti o ba goke de ipele yẹn lẹẹkan, ti o si lee de iwaju Ọlọrun - ki iṣe nipa ijilara, ṣugbọn nipa wipe ki Ẹmi Mimọ gbe ọ soke nitootọ - iwọ yoo ri i wipe a ti kọ “Ikabọdu” si gbogbo rẹ lara: Ogo Ọlọrun ti kuro ninu gbogbo ijọ ẹlẹkọ-adamọ. Bẹẹ ni. Ko si eyiti o tọ ninu wọn.

41 Ẹ jẹ ki n ya oruka kan fun yin. Ti mo ba ni patako lati kọ nkan si… Mo fẹ ki ẹ wo ibi yii. Emi yoo ya oruka kan bi eleyi. Emi yoo si ya oruka miiran sinu oruka yẹn; o di meji. Emi yoo si tun ya oruka miiran sinu oruka iyẹn naa; o di oruka mẹta, òbìrí mẹta. Iwọ niyẹn. Ọlọrun niyẹn. Ọlọrun ninu mẹta jẹ ẹyọkan, laisi mẹta, ki iṣe Ọlọrun. Ko lee farahan ni ọna miiran. Bẹẹni iwọ naa ko lee farahan lai jẹ ẹni abaramẹta ti o jẹ. Iyẹn ni ara, ẹmi, ati ọkàn. Laisi ọ̀kan ninu wọn, o kò pé. Ti o ko ba ni ọkàn, o ki yoo jẹ ohunkohun. Ti o ko ba ni ẹmi, o ki yoo jẹ ohunkohun. Ti o ko ba ni ara, iwọ yoo jẹ ẹmi - kiị se ara. Nitorinaa, Ọlọrun pe ninu ẹda kan ti o farahan ni ọna mẹta; ki iṣe ẹda mẹta ọtọọtọ, ṣugbọn ẹda kan ti o farahan ni ọna mẹta. Baba, Ọmọ, ati Ẹmi Mimọ jẹ Ọlọrun tootọ kannaa ti o farahan.

Ọlọrun…

42 Ẹ kiyesi ibi yii… Ẹ duro na. Mo gbagbọ wipe mo ka eyi ni iṣẹju melo kan sẹyin. Ẹ feti si eyi: “… si angẹli ijọ ni Laodikea, kọwe; Nkan wọnyi ni ẹniti ijẹ Amin wi, ẹlẹri olododo ati olootọ, olupilẹṣẹ ẹda Ọlọrun;”. Ọlọrun ni Ẹlẹda, bawo ni ą se wa da Oun? Ṣugbọn eyi ni ibẹrẹ iṣẹda Ọlọrun. Nigbati a da Ọlọrun ti iṣe Ẹmi ni irisi eniyan; Ọlọrun ni a da yẹn: Ọlọrun, Ẹlẹda funra Rẹ, Oun naa di ẹda. Ọlọrun ti o da ilẹ; ti o da egungun; ti o da kán-ún, imọlẹ iṣẹda, epo rọbi; o pa gbogbo rẹ pọ, O si da ara Rẹ, ni ibẹrẹ iṣẹda Ọlọrun - ẹniti iṣe Amin, opin. Amin tumọ si “bẹẹ ni ki o ri.” Opin Ọlọrun, nigbati Ọlọrun sọ iṣẹda Rẹ di pipe.

Bawo ni o ti ri bayi? Ko si ẹniti o ri Ọlọrun ri, ṣugbọn Ọmọ bibi kanṣoṣo ti Baba ni o fi i han. Ṣe o ye yin?

43 Ẹ duro na. Ẹ ko kanju. Ẹ jẹ ki a ṣí Kolose, fun iṣẹju kan. Iwe Mimọ kan ṣẹṣẹ wa si ọkan mi ni. Ẹ jẹ ki a ṣí Kolose, iwe Kolose, ki a ṣí … mo gbagbọ wipe ori kinni ni. Mo nilati wo eyi, nitori ko si lọkan mi tẹlẹ, nitorinaa, emi yoo… Bi mọ se maa n ṣe tẹlẹ, nigbati mo ṣì jẹ́ ọ̀dọ́ oniwaasu, mo lee ronu awọn nkan yẹn lẹsẹkẹsẹ,

ṣugbọn bi mo ṣe n dagba si i, emi ko lee… Ẹ jẹ ki a bẹrẹ lati ẹsẹ ikẹsan, mo gbagbọ wipe ẹsẹ ikẹsan ni.

Nitori eyi [Pọọlu niyi, o n sọ fun awọn ara Kolose nipa Kristi - ẹniti O jẹ.] Nitori eyi, lati ọjọ ti awa ti gbọ, awa pẹlu ko simi lati maa gbadura ati lati maa bẹbẹ fun yin pe ki ẹyin ki o lee kun fun imọ ifẹ rẹ ninu ọgbọn ati imoye gbogbo ti iṣe ti Ẹmi;

Ki ẹ lee maa rin ni yiyẹ ni ti Oluwa ati iwu gbogbo, ki ẹ maa so eso ninu iṣẹ rere gbogbo, ki ẹ si maa pọ si i ninu imọ Ọlọrun;

Ki a fi ipa … gbogbo … sọ yin di alagbara, gẹgẹbi agbara ogo rẹ, sinu suuru ati ipamọra gbogbo pẹlu ayọ;

Ki ẹ maa dupẹ lọwọ Baba, ẹniti o mu wa yẹ, ti o … mu wą se … alabapin ninu ogun awọn eniyan mimọ ninu imọlẹ…

Ẹniti o ti gba wa kuro lọwọ agbara okunkun, ti o si ṣí wa nipo sinu ijọba ayanfẹ ọmọ rẹ: [Ibiti a n lọ niyi. Ẹ kiyesi i.]

Ninu ẹniti awa ni idande nipa ẹjẹ rẹ, ani idariji ẹṣẹ:

Ẹniti iṣe aworan Ọlọrun ti a ko ri, [ṣe o ye yin? Ẹsẹ kẹẹdogun, Kolose 1:15] akọbi gbogbo ẹda.

Amin! Wipe kini? “Akọbi gbogbo ẹda.” Ibaa ṣe angẹli; ibaa ṣe ẹnikẹni ti o lee jẹ; Oun ni akọbi gbogbo ẹda.

Nitori ninu rẹ ni a ti da ohun gbogbo, [ni a ti da ohun gbogbo], ohun ti n bẹ ni ọrun, tabi ohun ti n bẹ ni aye, eyiti a ri, … ati eyiti a ko ri, wọn ibaa ṣe itẹ, tabi oye, … tabi ijọba, … tabi ọla,: nipasẹ rẹ ni a ti da ohun gbogbo, ati fun-un:

44 Ibaa ṣe ohunkohun ti o lee jẹ, ko si ẹda miiran. Ẹ kiyesi i.

Oun si … wa ṣaaju ohun gbogbo, ati ninu rẹ ni ohun gbogbo duro ṣọkan.

Ibaa ṣe Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ; ohunkohun ti o jẹ,

Oun si wa ṣaaju ohun gbogbo.

Ṣaaju ohun gbogbo ti o wa ni ọrun, ni aye, eyiti a ri, eyiti a ko ri, ohunkohun; Ọmọ Ọlọrun yii wa ṣaaju ohun gbogbo. Ṣe bẹẹ ni? Emi ko bikita, itẹ, ijọba, ohunkohun ti o jẹ, itẹ ọrun, ijọba, ohunkohun ti o jẹ. Awọn ipele iyanu loke lọhun, ninu awọn ainipẹkun, ibi yoowu ti o wà, ohunkohun yoowu ti o jẹ, awọn angẹli, awọn ọlọrun, ohunkohun ti o jẹ, “…Oun wa ṣaaju ohun gbogbo.” Amin! Sẹ e ko ri i ni? “Oun wa ṣaaju ohun gbogbo” ati “nipasẹ rẹ ni a ti da ohun gbogbo.”

Oun … ẹsẹ kẹtadinlogun bayi:

Oun si wa ṣaaju ohun gbogbo, ati ninu rẹ ni ohun gbogbo duro ṣọkan.

45 Ko si ohun ti o lee ṣiṣẹ laisi Oun. Ibaa ṣe Ọlọrun Baba, Ọlọrun Ẹmi Mimọ; ibaa ṣe awọn angẹli, ipa, agbara, ijọba, ohunkohun yoowu ti o jẹ - nipasẹ Rẹ ni ohun gbogbo fi n ṣiṣẹ. Ohun gbogbo duro ṣọkan ninu Rẹ.

Oun si ni ori fun ara, ẹyinni ni ijọ; ẹniti iṣe ipilẹṣẹ, [Ẹniti iṣe ipilẹṣẹ!] akọbi lati inu oku wa; [ẹniti a ji dide nigbati O wa ṣe irapada] pe ninu ohun gbogbo, ki oun ki o lee ni ipo ti o ga julọ.

Nini ipo ti o ga julọ - ṣe ẹ mọ ohun ti iyẹn tumọ si? Iyẹn ni pe O wa lori ohun gbogbo. O wa lori ohun gbogbo ti a da: gbogbo angẹli, gbogbo ẹda, ohun yoowu … ohun gbogbo ti o wa - Oun wa lori ohun gbogbo. Ẹda wo niyi? Tani o lee jẹ? Lori ohun gbogbo.

Lẹyin ti o ti ṣe ilaja,…

Ẹ jẹ ki a wo o fun iṣẹju kan.

Nitori didun inu Baba ni pe ki ẹkun gbogbo lee maa gbe inu rẹ;

Ẹkun ohun gbogbo, gbogbo ẹkun Ọlọrun, gbogbo ẹkun awọn angẹli, gbogbo ẹkun akoko, gbogbo ẹkun ainipẹkun - ohun gbogbo n gbe inu Rẹ. Ẹni naa niyẹn.

Ati nipasẹ rẹ lati ba ohun gbogbo laja, lẹyin ti o ti fi ẹjẹ agbelebu rẹ pari ija; mo ni, nipasẹ rẹ, wọn ibaa ṣe

ohun ti n bẹ ni aye, tabi ohun ti n bẹ ni ọrun.

Ẹni nla naa niyẹn, ti a n sọrọ nipa rẹ, nibi ibẹrẹ iṣẹda Ọlọrun.

46 Ni bayi ti ijọ - gbogbo ipinnu Rẹ ni ijọ… Bawo ni a ṣe n wọ inu ijọ yii? Nipa Ẹmi kan ni a baptiisi gbogbo wa sinu ara kan: iyẹn ijọ, ti iṣe ara Kristi. Ko lee kuna. Ohun ti o ṣẹlẹ niyi. Ẹ kiyesi aworan afiwe yii.

Ẹni ti ita yii ni ẹran-ara. Iyẹn ni a n wo, ohun ti a n ri. Ọna marun-un ni o wọ inu ara naa. Ọmọ yoowu ti o ba lọ si ile-iwe girama, bii temi, yoo mọ wipe onmọ marun-un ni o n ṣakoso ara: iriran, itọwo, imọlara, igboorun ati igbọran. Laisi iyẹn, o ko lee fọwọ kan ara. Ọna kanṣoṣo ti o fi lee fọwọ kan ara niyẹn - iriran, itọwo, imọlara, igboorun ati igbọran. O ri i, o tọ ọ wo, o mọ ọ lara. Ẹni ibi naa niyẹn, ti o wa ni ita.

47 Ninu iyẹn ni ẹmi wa, eyiti o jẹ nigbati a ba bi ọ sibi yii, ti a si mi eemi iye si inu rẹ. Ẹmi yẹn ni iwa-ẹda ti aye, nitori ki iṣe Ọlọrun ni o fi funni, ṣugbọn a fi funni … Ọlọrun fi aaye gba a. Ṣe iyẹn ye yin bayi?

Nitori gbogbo ọmọ ti a bi sinu aye ni a bi ninu ẹṣẹ, ti a mọ ninu aiṣedeedee; o wa sinu aye, o n sọ iro jade lẹnu. Ṣe bẹẹ ni?

Nitorinaa, ẹni yẹn, ti o wa ninu ibi yii, ẹlẹṣẹ ni lati ilẹ wa. Ṣugbọn ni bayi, o ni ọna marun-un, awọn ọna marun-un naa (emi ko mọ boya mo lee sọ wọn lati ori bayi) ekinni, ti mo mọ, ni ero, ẹri-ọkan, ati ifẹ - yiyan, (rara) ẹri-ọkan, ifẹ, ironu: awọn ọna marun-un ni o wọ inu ẹmi. O ko lee fi ẹran-ara rẹ ronu; ẹmi ni o lee fi ronu. O ko lee ni ẹri-ọkan ninu ẹran-ara rẹ. Ko ni ọpọlọ rara - ara rẹ ko ni i. Nitorinaa, ẹmi rẹ ni o nilati fi ronu. O nilati ronu. O ko lee fi ẹran-ara rẹ ronu, nitori ironu kii riran, tọwo, ni imọlara, gboorun tabi gbọran. Ironu jẹ ohun ti o nilati ṣe ninu ọkan rẹ.

Ti o ba sun tabi ti o daku; ara rẹ wa nilẹ bi oku, ṣugbọn ẹmi rẹ ṣì lee ronu. Onmọ marun-un ni o n ṣakoso ẹni ti inu yẹn. Si ẹniti o kẹyin bayi, eyiti iṣe ọkan… Onmọ kanṣoṣo ni o n ṣakoso iyẹn, iyẹn ni ominira lati yan, ominira lati gba tabi lati kọ.

48 Ni bayi, idi ti awọn eniyan loni - ẹ maṣe gbagbe eleyi, ẹ o si ri ohun ti Ẹmi Mimọ … ohun ti o jẹ ẹri akọkọ wipe eniyan ni Ẹmi Mimọ, ṣe ẹ gbọ. Awọn eniyan lee gbe ninu ẹmi yii, wọn si maa n jo ninu ẹmi. Wọn maa n pariwo ninu ẹmi. Wọn maa n lọ si ile-ijọsin ninu ẹmi, lootọ, a lee fi Ẹmi Ọlọrun ta ami-ororo si ẹmi yẹn, ṣugbọn sibẹ ki o sọnu, ki o si kun fun ẹmi eṣu gan-an ninu ẹmi yẹn. Nitori…

Ẹ kiyesi i. Idi niyẹn ti ẹ ko fi lee sọ fun obinrin yẹn, wipe wiwọ ṣokoto penpe lodi. O ko lee sọ fun-un wipe gige irun rẹ lodi. “O dara, kini irun rẹ nį se pẹlu rẹ̀?” Ko buru, o nį se pẹlu rẹ fun Samsoni, ṣe ẹ ri i. “Ẹnikẹni ti o ba fi ọrọ kan kun eyi, tabi ti o yo ọrọ kan kuro ninu rẹ…” O nilati ni paripari kan nibikan.

49 Fun apẹẹrẹ bayi, ti mo ba jẹ ọmọ ijọ Onitẹbọmi, ti o si wa sọ fun mi wipe a gbọdọ baptiisi mi ni orukọ Jesu Kristi: o wa ninu Bibeli. Ohun ti yoo ṣẹlẹ ni wipe, n o sọ pe, “Emi yoo beere lọwọ oluṣọ-aguntan mi.”

Ki n wa lọ sọdọ oluṣọ-aguntan mi, ki o si wipe, “Ah, aye atijọ niyẹn, ṣe o ye ọ. Awa ijọ Onitẹbọmi … ohun ti a gbagbọ niyi: A gbagbọ wipe a nilati tẹ wa bọ inu omi ni orukọ Baba, Ọmọ, Ẹmi Mimọ. Bi gbogbo awọn ijọ ti n ṣe e niyẹn. Lati igba ti John Smith ti da a silẹ, bi a ti n ṣe e niyẹn.”

Paripari tirẹ niyẹn. “[awọn ọrọ ibi yii ko ja gaara] pẹlu ohun ti ẹni yẹn sọ!”

50 Ti o ba jẹ ọmọ ijọ Eleto nkọ, ti o jẹ wipe bibu omi wọnni ni ilana tiyin, ti a wa sọ fun ọ wipe a nilati tẹ ọ bọ inu omi? Ṣe ẹ ri ohun ti mo n sọ? Ki o wa pada lọ sọdọ oluṣọ-aguntan ijọ Eleto, ki oun naa kọ iwe beere lọwọ bisọọbu, wipe lagbaja sọ “bayi” nipa nkan yii. “Ṣugbọn awa ijọ Eleto, eyiti a da silẹ ni ọọdunrun tabi irinwo ọdun sẹyin ni England lati ọwọ John Wesley ati Whitfield, ati gbogbo awọn ti o ku; ati Asbury, awa ni a kọ iwe yii, a n tẹle John Wesley, wipe a nilati bu omi wọnni ni, nitoriti o jẹ ijẹwọ ti ita. A si ro wipe bibu omi wọnni dara bii gbogbo awọn ọna miiran.”

Ti o ba jẹ ojulowo… Ti ijọ Eleto ba jẹ paripari rẹ, o ko lee lọ ju bẹyẹn lọ.

Ti o ba jẹ ọmọ ijọ Katoliiki… Jẹ ki n sọ fun ọ, ko si ninu Bibeli wipe ki a maṣe jẹ ẹran ni ọjọ Friday, ati gbogbo awọn nkan wọnyi, ati wipe Ounjẹ Alẹ Oluwa kii ṣe akara lasan, nitori Ẹmi ni, ati bẹẹ bẹẹ lọ, ki o lọ sọdọ alufaa rẹ, ki alufaa naa si wipe, “Oun ni a kọ sinu iwe akọsilẹ wa yii.” Ti ijọ ba jẹ paripari rẹ, iwọ ki yoo bikita fun ohunkohun ti ẹnikẹni ba sọ. Paripari rẹ niyẹn.

Ọlọrun jọwọ jẹ ki eyi wọ inu ọkan lọ!

Ni temi, gbogbo rẹ ni o lodi. Ọrọ Ọlọrun nikan ni paripari! Ohunkohun ti Ọrọ yẹn ba sọ, iyẹn ni o jẹ otitọ.

51 Ọna kanṣoṣo ti o fi lee goke wa sibi yii, lati wa ninu ẹni ti inu yii, a nilati yan ọ tẹlẹ, nitori o ti wa pẹlu

Ọlọrun tẹlẹ; o jẹ ara Ọlọrun.

Mo wa ninu baba mi tẹlẹ. Mo wa ninu baba-baba mi pẹlu, ati baba-baba-baba mi. Nipa iru, mo wa nibẹ. Bẹẹni mo ṣe wa ninu Kristi tẹlẹ! O wa ninu Kristi ṣaaju ipilẹṣẹ aye! Awọn Tirẹ ni Ó wá lati ra pada - awọn Tirẹ ti o wa ninu Rẹ. Halleluyah! Awọn ọmọ Rẹ ti o wa ninu Rẹ.

Ko wa lati gba awọn ọmọ eṣu la. Wọn ko lee mọ ọ laelae. Wọn si gbọn pupọ ninu ẹkọ ọpọlọ wọn, tobẹẹ ti o ko lee fi ara we wọn rara. O ko lee sọrọ ju wọn lọ. Ṣugbọn nipa igbagbọ, iwọ ri i.

52 Imọ-ijinlẹ ko nilo igbagbọ kankan. Imọ-ijinlẹ n fi ohun ti wọn n sọ han. Ko nilo igbagbọ kankan.

Alufaa Katoliiki yoo sọ fun ọ wipe, “Wo bi ọ́ se pẹ to ti ijọ Katoliiki ti wa. Wo bi o ṣe duro gbọingbọin labẹ inunibini awọn abọriṣa.” Ijọ Eleto yoo wipe, “Wo o. O ti pẹ to…”

53 Mo ri ijọ kan… Ti a ba n sọrọ nipa ami agabagebe. Bi mọ se n bọ loju ọna lana, mo ri i … o ni, “Ijọ Kristi, a da a silẹ ni AD 33.” Ko tii pe ọgọrun ọdun o, ṣe ẹ ri i - ijọ ẹlẹkọ-adamọ lasan.

Kai, ẹkọ awọn aposteli - wọn ko ni nkankan rara. Awọn ni Sadusi ode oni. Ko si ẹmi, ko si… O ko si lee sọ fun wọn. O ko lee ba wọn sọrọ; o ko lee ba wọn jiroro, nitori awa kọja ero ọpọlọ. “Maṣe tẹ si imọ ara rẹ.” Igbagbọ kii lo ero ọpọlọ rara. Igbagbọ maa n gba a gbọ ni. Wọn ni, “Wo ibi bayi. Ṣe o ro wipe a nilati ṣe awọn nkan ti wọn n ṣe ni igba yẹn? Isọkusọ.” Ṣugbọn Bibeli sọ bẹẹ. Emi ko lee ṣalaye bi o ṣe n ṣẹlẹ, ṣugbọn o n ṣẹlẹ. Ọlọrun sọ bẹẹ. Nitorinaa, o ko nilati… Emi ko lee sọ ohunkohun fun ọ nipa rẹ.

Igbagbọ kii ṣalaye rẹ. Ṣe ẹ mọ bẹẹ? Igbagbọ kan maa n gba a gbọ ni.

54 Jesu sọ bẹẹ fun Nikodemu lati inu igbimọ ijọ ọjọ Rẹ; o tọ Ọ wa ni oru, o wipe, “Olukọni, awa mọ wipe olukọ ni Iwọ, lati ọdọ Ọlọrun wa, nitori ko si ẹniti o lee ṣe ohun ti Iwọ n ṣe, bikoṣepe Ọlọrun wa pẹlu rẹ.”

O ni, “Lootọ ni mo wi fun ọ, bikoṣepe a tun eniyan bi, oun ko lee ri ijọba Ọlọrun.”

O ni, “Emi, agbalagba, ki n tun wọ inu iya mi lọ, ki a si bi mi?

O ni, “Ni bayi, bawo ni mo ṣe lee sọ awọn nkan ti ọrun fun ọ, nigbati o ko gba awọn nkan ti aye gbọ?”

55 O wa sọ lọjọ kan wipe, “Bikoṣepe ẹ ba jẹ ẹran-ara Ọmọ Eniyan, ki ẹ si mu ẹjẹ rẹ, ẹ ko ni iye ninu yin.” Ko ṣalaye rẹ.

Awọn aposteli wọnyẹn, ati awọn ti a yan tẹlẹ si iye ni igba yẹn, O mọ wọn. O ni, “Gbogbo awọn ti Baba ti fi fun mi yoo wa. (Ohun kanṣọṣo ti O nilati ṣe ni ki o sọ ohùn mi di mimọ; wọn mọ ọ.) Nitori awọn aguntan mi mọ ohun mi.” Ohùn jẹ ọrọ ti a sọ jade… Wọn gba a gbọ lọnakọna. Wọn ko nilo lati fidi ohunkohun mulẹ nipa imọ-ijinlẹ, tabi ki wọn beere lọwọ Sadusi tabi Farisi tabi ẹnikẹni nipa rẹ. “Mo sọ ọ, wọn gba a gbọ. Nitori awọn aguntan mọ ohùn mi.” Ohùn Ọlọrun si niyi gẹgẹbi iwe ti a kọ silẹ, nitori eyi ni gbogbo ifihan Jesu Kristi, Majẹmu Laelae ati Titun papọ. Amin! Bi o ṣe ri niyẹn.

56 Eeṣe? O sọ pe eniyan rere ni awọn eniyan wọnyi. Ki lo ṣe wọn? Ohun kan ni: inu ijọ ni opomulero wọn wa. Nibi yii ẹwẹ…

Ṣe ẹ ranti ọjọ Sunday ọsẹ kan sẹyin…? Ẹni melo ni o wa nibi ti o si gbọ iwaasu lori Awọn Ẹni Ami-ororo Ni Ikẹyin Ọjọ? Mo ro wipe gbogbo yin ni. Ẹ wo o, wọn ni ami-ororo. A ta ami-ororo si ẹmi wọn ni ipele keji yii.

57 Obinrin akọkọ sọ pe, “Bẹẹkọ.” Ko bikita ohun ti ijọ sọ, tabi ohun ti ẹnikẹni sọ. O jafafa. O ka iwe. O lee fi juujuu bo ọkọ rẹ loju, o si ro wipe oun jafafa nipa ṣiṣe bẹẹ.

Obinrin keji yii wa ni ihooho, o fọju, ko si mọ ọ. O ṣe ni laanu, ṣugbọn ohun ti Bibeli n fihan fun wa niyẹn.

O n lọ si ile-ijọsin. Obinrin yẹn… Iba kuku dara… Obinrin yẹn yoo jẹ… O n gbe igbe-aye ti o mọ. Ko si ohun ti o lodi si iyẹn. Ọlọrun ni Onidajọ iyẹn. Emi ko mọ; emi kii ṣe onidajọ. Ohun ti O ba fihan mi nikan ni n o jiyin fun.

Ohun ti awọn aposteli sọ niyẹn: “Awa n sọ ohun ti a mọ, ohun ti a gbọ, ohun ti a ti ri.” Ohun ti mo ni ojuṣe fun niyẹn. Ohun ti iwọ naa ni ojuṣe fun niyẹn.

58 Ṣugbọn ni bayi, ti o ba mu obinrin yẹn naa… Nibo ni o pari rẹ si? O n lọ kaakiri. O gbọ; ọpọ igba ni o n ṣí redio. Ohùn Ọlọrun ti n sọrọ ni ọpọlọpọ igba.

Ẹ wo o, o wa sinu ẹgbẹ awo yii, ẹgbẹ ẹya kan - gbogbo awọn ijọ jẹ ẹgbẹ, gbogbo wọn. Otitọ niyẹn. Ẹgbẹ awo ni wọn, nibi ti awọn eniyan n darapọ gẹgẹbi ọmọ ẹgbẹ. O wa sibẹ; iyẹn tẹ ẹ lọrun. Ti o ba lọ sọ ohun ti o

yẹ ki o ṣe fun-un, ki yoo feti si ọ. Fi han-an ninu Bibeli; ki yoo feti silẹ.

59 Arakunrin ati arabinrin mi ọwọn, o ku ọrọ kan tabi meji si i, ki a to danu duro; iṣẹju mẹẹdogun ni o ku … a o jade ni iṣẹju mẹẹdogun si i.

60 Ẹ wo o, mo fẹ beere nkankan lọwọ yin. Ki lo fa a ti obinrin yẹn ko fi ri i? Ki lo fa ti ko ri i? Niti gbigbe igbe-aye panṣaga nipa ti ara si ọkọ rẹ, ko jẹbi; ko ni ohun kan lati jẹwọ rẹ. O mọ gẹgẹbi o ti mọ ni ọjọ ti a bi i; ọkunrin kankan ko fi ọwọ kan-an ri. Mo n sọrọ nipa obinrin inu ijọ bayi. O mọ bii ọjọ ti a bi i.

Ohun ti ijọ jẹ niyẹn. A bi i nitootọ, ṣugbọn a bi i ninu ẹṣẹ, a mọ ọ ninu aiṣedeedee. Ṣe ẹ ri ohun ti mo n sọ?

Iwọ sọ fun-un wipe o lodi fun-un lati ge irun rẹ. Bibeli sọ bẹẹ. O lodi fun-un lati maa wọ awọn ṣokoto penpe. Bibeli sọ bẹẹ. Yoo wipe, “Isọkusọ.” Kini idi? Idakọro rẹ ko si ninu ẹnikẹta yẹn - ọkan ti a ti yan tẹlẹ ti a si ran wa lati ọdọ Ọlọrun - ṣugbọn inu ijọ eniyan kan ni idakọro rẹ wa, eyiti eniyan kan da silẹ yatọ si eyi, ṣe ẹ ri i.

61 Ṣugbọn ti Ọrọ Ọlọrun ba wa ninu ọkan yẹn, yoo sọ pe “Amin, o ye mi.” Yoo tẹle e.

Ẹ wo o bayi. Nitorinaa, ẹniti a ti ipasẹ Ẹmi Ọlọrun bi… Ẹran-ara niyi bayi. Aarin takọ-tabo ni mo ti n sọrọ yii, ṣugbọn mo n sọrọ gẹgẹbi oluṣọ-aguntan yin, gẹgẹbi arakunrin yin. Ẹran-ara niyi; o jẹ alailera. Dandan ni ki o ri bẹẹ. Bi ọmọbinrin kan ba n rin loju titi, ti ọdọmọkunrin kan, ti o jẹ ọdọ, ọmọ ọdun mẹtadinlogun, mejidinlogun, ogun ọdun, ọdun mẹẹdọgbọn, tabi ọgbọn ọdun, ba rin nitosi ibẹ; ti ọdọmọbinrin yii si wa, ti o n lọ́ ara rẹ, ti o n rin pẹlu bata ti o ga; ti aṣọ rẹ yọ sita niwaju ati lẹyin, ti aṣọ rẹ si fo soke kọja orunkun, tabi ti o wọ ṣokoto penpe sidi. Njẹ ẹ mọ wipe Bibeli sọ wipe yoo ṣe bẹẹ? Ẹ mọ, Bibeli sọ wipe bi wọn yoo ti ṣe niyẹn, wọn yoo jẹ ẹlẹgbin.

62 Ṣe ẹ ka eyi nibi yii … iwe Reader's Digest ti oṣu yii, wipe awọn ọkunrin ati awọn obinrin ọjọ oni … awọn ọmọdebinrin lati ogun ọdun si ọdun mẹẹdọgbọn ko ri nkan oṣu wọn mọ; wipe igbe-aye yin n yipada ni agbedemeji aye yin, ni ibamu pẹlu imọ-ijinlẹ, laarin ogun ọdun si ọdun mẹẹdọgbọn. Ni igba temi, ọgbọn ọdun si ọdun marundinlogoji ni; ni igba iya mi, obinrin ko lee dẹkun riri nkan oṣu rẹ laijẹ wipe o pe ọmọ ogoji ọdun tabi ọdun marundinlaadọta. Ki lo ṣẹlẹ? Nipa imọ-ijinlẹ ni, ati awọn ounjẹ, ounjẹ adamọdi, eyiti o ti ba gbogbo ara eniyan jẹ, tobẹẹ ti a ni kiki awọn … kiki idibajẹ. Njẹ ti ẹran-ara ba ti bajẹ, ṣe ki iṣe inu ẹran-ara yẹn naa ni ọpọlọ wa ni?

63 Ẹ kiyesi ẹmi ti o n tẹle e. Akoko kan n bọ, ni orukọ Oluwa, ti awọn eniyan yoo ya were patapata. Bibeli sọ bẹẹ. Wọn yoo maa pariwo, wọn yoo si maa kigbe; ironu ti o ba ni lẹru yoo maa wa si ọkan wọn. Awọn redio wọn, ati awọn eto ori tẹlifisan wọn n ṣe e. Awọn nkankan yoo wa bi ẹni wipe eera ga si ilẹ ni nkan bii giga igi mẹrinla. Awọn nkan yoo wa … ẹyẹ yoo fo kọja ninu aye pẹlu apa rẹ ti o gun to maili mẹrin tabi marun-un, awọn eniyan yoo ri wọn; wọn yoo pariwo, wọn yoo kigbe, wọn yoo si bẹbẹ fun aanu, ṣugbọn yoo jẹ iyọnu. Ẹ duro de igba ti n o waasu lori awọn iyọnu ti o n bọ.

64 Ẹ kiyesi ohun ti Mose ṣe ninu ara, kii ṣe ninu Ẹmi. Nigbati o wipe, “Mose…” Ọlọrun sọ fun Mose, pe, “Jade lọ sibẹyẹn,” (si wolii Rẹ) “bu erupẹ kun ọwọ rẹ; da a si ofuurufu, ki o si wipe, 'Bayi ni Oluwa wi,' awọn eṣinṣin yoo wa sori ilẹ aye.” Ko si eṣinṣin kankan. Ki a to mọ ohun ti o n ṣẹlẹ, wọn bẹrẹ si ri nkankan ti o n fa ninu igbo. Wọn wo ibẹ, omiran tun ti wa nibẹ. Lẹyin igba diẹ, wọn ti pọ gan-an tobẹẹ ti o ko lee rin kọja laarin wọn. Nibo ni wọn ti wa? Ọlọrun ni Ẹlẹda. O lee ṣe ohun ti o wu u. Aṣeyoowuu ni. O lee da ẹyẹ ti iyẹ apa rẹ yoo de ipẹkun ọrun lọtun ati losi.

O ni, “Ki eṣinṣin ki o wa, ki o bo gbogbo aye mọlẹ.” Ko si eṣinṣin ni ilẹ naa. Ohun ti a ri ni wipe, eṣinṣin nla kan bẹrẹ si fo kiri. Kiakia, wọn ti pe mẹjọ, mẹwa, mejila. Ka to wi, ka to fọ, o ko lee rin kọja laarin wọn. Ọlọrun Ẹlẹda maa n mu ọrọ Rẹ ṣẹ.

65 O na ọpa rẹ nipa aṣẹ Ọlọrun, o wipe, “Ki ọpọlọ jade wa, ki wọn si bo ilẹ.” Awọn ọpọlọ si wa, tobẹẹ ti wọn n ko wọn jọ ni iti - oorun wa nibi gbogbo - boya awọn ọpọlọ naa ga silẹ ni iwọn ẹsẹ bata ogoji tabi aadọta. Wọn wa ninu apoti aṣọ Farao. Wọn wa ni … ti o ba ṣí aṣọ, awọn ẹẹdẹgbẹta ọpọlọ yoo wa labẹ aṣọ, labẹ ibusun, labẹ ẹni àtẹ́ẹ̀ká. Ọpọlọ wa nibigbogbo. Nibo ni wọn ti wa? Aṣeyoowuu ni Ọlọrun Ẹlẹda. Ohun ti O ba sọ ni O n ṣe.

O sọ pe awọn ohun ẹru yoo wa lori ilẹ aye: awọn eeṣu ti irun wọn dabi irun ori obinrin - irun gigun - lati dọdẹ awọn obinrin ti wọn n ge irun wọn; eyin wọn yoo dabi ti kiniun, oró yoo wa nibi iru wọn bii ti akeekee. Wọn yoo da awọn eniyan loro fun ọpọlọpọ oṣu.

Ẹ duro de igba ti a o ṣí awọn iyọnu, ati awọn edidi, ati awọn ara meje wọnyẹn. Ẹ wo ohun ti yoo ṣẹlẹ. Ah, arakunrin, yara tete lọ si Goṣeni nigbati akoko ṣì wa lati lọ si Goṣeni. Maṣe kiyesi ohun ti ara yii.

66 Ẹ wo o, obinrin kan niyi, ti o n rọ kẹkẹ loju titi. Ọdọmọkunrin kan niyi, oju rẹ ti wọ ọ - ọmọ ijọ si ni oun; ọmọ ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ, tabi ohun yoowu ti o jẹ - ṣugbọn ohun ti a ri ni wipe, ko ni idakọrọ kankan ninu rẹ.

Ọmọbinrin naa yoo wipe, “Pẹlẹ o.” O ni irun ti o lọ́, oju rẹ si dara lati wo; ọdọmọkunrin naa naro ṣanṣan, boya o n gbiyanju lati gbe igbe-aye ti o dara. Ọmọbinrin naa yoo lọ ba a - oniwaasu tilẹ ni. Ohun ti a ri ti o ṣẹlẹ… Kini? Ti ita yii - ifẹ ẹran-ara - ẹmi si wa ninu, o ni ami-ororo, o wipe, “Ma ṣe e, ma ṣe e.” Ṣugbọn kini yoo ṣe? Yoo lọ kaakiri, yoo mu … o lọ niyẹn. Ohun ti yoo ṣẹlẹ ni wipe o n gbiyanju lati gbe e jade. O ti jẹbi ṣiṣe panṣaga, boya o fi ọwọ kan-an tabi bẹẹkọ.

67 Ṣugbọn ọmọkunrin Ọlọrun ti a ti tun bi nitootọ… Amin!

O ko lee ṣe e funra rẹ. Ko ṣee ṣe rara fun ọmọkunrin ti ara rẹ pe lati rin kọja niwaju iru obinrin bẹyẹn, lai jẹ wipe nkankan ṣẹlẹ. Ṣugbọn ti nkankan ba ti wa ni inu, ohun kekere kan ti a ti tun bi yẹn… O ṣee ṣe ki ọkunrin yẹn ti pariwo, ki o fedefọ, ki o fo soke, ki o jo, ati ohun gbogbo bẹẹ; ki Ẹmi ta ami-ororo si i; ki ọ se gbogbo iṣẹ-ami ati iṣẹ-ara ti Ọlọrun sọ nibẹ. Nipa Ẹmi Rẹ…

Jesu wipe, “Ọpọ ni yoo tọ mi wa ni ọjọ naa, ti wọn yoo wipe, 'Oluwa, emi ko ha ti sọtẹlẹ ni orukọ rẹ? Emi ko ha ti le ẹmi eṣu jade ni orukọ rẹ? Emi ko ha ti…?” O ni, “Ẹ kuro lọdọ mi, ẹyin oniṣẹ ẹṣẹ.” Kini ẹṣẹ? Ohun kan ti o mọ wipe o yẹ ki o ṣe, ṣugbọn ti o kọ lati ṣe e. “Ẹ kuro lọdọ mi, ẹyin oniṣẹ ẹṣẹ, emi ko mọ yin ri.”

Ṣugbọn ninu ọkan ọkunrin yẹn… Ti opomulero yẹn ba wa nibẹ, iru iye Ọlọrun ti a ti yan tẹlẹ ṣaaju ipilẹṣẹ aye - emi ko bikita ohun ti o ṣẹlẹ - yoo gbe e ro; o ti wa nibẹ.

68 Idi niyẹn ti obinrin yẹn yoo fi wọ ṣokoto penpe. A ka a si aṣẹwo gẹgẹbi obinrin ti o ṣe ìṣe naa, ṣe ẹ ri i. Ko mọ wipe ẹmi yẹn… Bawo ni o ṣe mọ paripari rẹ̀? Kini paripari? Ọrọ ti o kẹyin ni. Paripari ni Amin; oun ni opin gbogbo iyan jija - paripari rẹ.

Ti ijọ rẹ … ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ti o sọ fun ọ wipe irun gigun jẹ gbawere-mẹsin - “Taya kan wa ni ipakọ rẹ,” ati bẹẹ bẹẹ lọ, ati iru awọn nkan bẹyẹn - ọkunrin yẹn ni ẹmi eṣu; nitori Ọrọ Ọlọrun wipe, “Ohun itiju ni fun obinrin lati ge irun rẹ. Yoo ṣe aibọwọ fun ori rẹ.” Ti o ba ṣe aibọwọ fun ọkọ rẹ, ti ọkọ rẹ si jẹ ijọ, ti ijọ si jẹ Kristi, o jẹ alailọla aṣẹwo ẹlẹsin, o wa ni ihooho, ko si mọ ọ. Ni ihooho. Ṣe Bibeli ko ti sọ ni, wipe ibori obinrin ni irun rẹ? Ṣe a ko fi irun rẹ fun-un fun ibori ni?

69 Lọjọ kan nibi itẹ idajọ… Mo ti gbiyanju lati da oogun si wọn lẹnu, mo si fi ọwọ mi di i mu, ẹ si tun tu u jade laarin ọwọ naa. Ṣugbọn Ọlọrun yoo da wọn lẹjọ lọjọ kan. “Bayi ni Oluwa wi” niyẹn. Kiị se iwa omugọ kankan, tabi baba arugbo kan ti ori rẹ ti yi. Kii ṣe bẹẹ, nitori Ọrọ Oluwa ni.

Kristẹni tootọ yoo tẹle ẹni ti inu yẹn: Ẹmi ti o wa ni atetekọṣe, eyiti iṣẹ Ọrọ naa. Gẹgẹbi O ti jẹ gbogbo ẹkunrẹrẹ rẹ, o wa ninu Rẹ ni Kalfari.

O ti mọ tẹlẹ wipe iwọ yoo wa nihin. O kan sọ ohun ti yoo ṣẹlẹ ni. Iwọ si wa ninu Rẹ. O ku pẹlu Rẹ. O ku si igberaga rẹ, o ku si ifẹkufẹ rẹ, o ku si aye. O ku pẹlu Rẹ ni Kalfari, o si jinde pẹlu Rẹ nigbati O jinde ni ọjọ kẹta; nitoriti o gba a, o joko sinu awọn ọrun bayi, ninu Kristi Jesu. Halleluyah!

70 Bi ọ se ri niyẹn. Ẹni ti inu yẹn ni, ẹni ti inu yẹn ni yoo gba Ọrọ naa, yoo duro ti Ọrọ naa laibikita. O ko lee ṣe ki o ma ṣe bẹẹ. Mo ti kọ́ iyẹn ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin.

Ọmọdebinrin mi wa nibẹ, o n ku lọ; iyawo mi wa ninu ile igbokupamọsi, wọn da ororo ikunra si ara rẹ, wọn si tẹ ẹ sibẹ. Wọn pe mi jade sibẹ wipe, Sharon n ku lọ. Idanwo ti o le ju ti mo tii ba pade ni gbogbo ọjọ aye mi niyẹn. Mo jẹ bii ọmọ ọdun mẹẹdọgbọn nigbanaa. Mo lọ sibẹ, Billy Paul naa wa loju iku.

Dokita Sam wá, o wipe, “Bill, emi ko ro wipe a lee doola ẹmi Billy.” O ni, “O buru jai.” O ni, “Bill, aanu rẹ ṣe mi.” O fi ọwọ rẹ kọ mi lọrun.

Mo ni, “Doc, emi ko ni okun mọ.” Ni wakati melo kan si i, wọn n pe ọmọ mi, Sharon; wọn sare gbe e lọ sibẹ. O ti n pọkaka iku; ko si dawo duro. Wọn ki abẹrẹ bọ ọpa ẹyin rẹ; wọn lu iho si i, wọn si mu nkan yii jade wa: arun ikọ awugbẹ ni.

71 Mo sare lọ si ile iwosan; mo gbe ọkọ mi si ita nibẹ, mo si jade, mo n rin lọ sinu iyara naa. Sam wa pẹlu fila rẹ ni ọwọ rẹ, o n sọkun; o fi ọwọ rẹ kọ mi lọrun, o wipe, “Pada wa, Bill.”

Mo ni, “Ki lo ṣẹlẹ.”

O ni, “O ko lee ri i. O ti fẹrẹ ku, Bill.”

Mo ni, “Rara, Sam, kii ṣe ọmọ mi.”

O ni, “Bẹẹni, oun ni.” O ni, “Ma tilẹ beere rẹ, Bill; ti ó ba tilẹ ye, ko lee jẹ eniyan mọ.” O ni yoo ya arọ ni, yoo si maa jẹ oró ni gbogbo ọjọ aye rẹ. O ni, “Arun ọpọlọ mọ ọpa ẹyin ni o ni.” O ni, “Maṣe lọ si itosi rẹ. Iwọ yoo pa Billy nipa ṣiṣẹ bẹẹ.”

Mo ni, “Sam, mo nilati ri i.”

O ni, “O ko leẹ se bẹẹ, Bill. N ko fẹ ki o ṣe bẹẹ. O mọ bi mo ṣe fẹran rẹ to. Iwọ jẹ ọrẹ ati ohun gbogbo fun mi.” O ni, “O mọ bi mo ṣe fẹran rẹ to,” o ni, “o mọ bi mọ se gba ọ gbọ to, Bill.” O ni, “Maṣe lọ sọdọ ọmọ-ọwọ yẹn.” O ni, “Ti o ba ṣe bẹẹ, arun yẹn wa lara rẹ̀, ṣe o ye ọ,” o ni, “oun yoo lọ ni iṣẹju melo kan si i,” o ni, “a o sin-in.” O ni, “Bill, aanu rẹ ṣe mi gan-an ni.”

72 O pe nọọsi lati fun mi ni oogun kan. O ni, “Emi ko mọ bi ọkunrin naa ṣe lee naro.”

Mo duro sibẹ fun igba diẹ. O mu oogun naa wa, mo si joko sinu gbọngan nibẹ. O ni, “Joko,” nọọsi naa si wipe, “Mo fẹ ki o mu eleyi, Arakunrin Branham.”

Mo ni, “O ṣeun, gbe e silẹ fun igba diẹ na.”

Nigbati o kuro, mo da a nu, mo si gbe ife naa kalẹ. Mo ni, “Ah, Ọlọrun, kini mo ṣe? Ọlọrun rere ni Ọ. Eeṣe ti O fi jẹ ki o ku?”; mo di ọwọ rẹ mejeeji mu, mo n bẹ Ọlọrun fun-un. “Eeṣe ti O fi jẹ ki o lọ? Billy ni o tun wa nibẹyẹn, oun naa n ku lọ, eleyi naa n ku lọ. Kini mo ṣe? Sọ fun mi! Oluwa, o dara ki emi naa kuku lọ pẹlu wọn.” Mo ṣí ilẹkun, ko si nọọsi kankan nibẹ, mo si yọ wọ ibẹ. Iyẹn ki wọn to tun ile-iwosan naa ṣe. O fẹrẹ ma si aṣọ iboju loju ferese; awọn eṣinṣin wa ni oju rẹ. Mo ni àwọ̀n ti a fi n le awọn ẹfọn lọwọ mi, a n pe e ni - àwọ̀n - mo fi bo oju rẹ. Mo le awọn eṣinṣin kuro; o dubulẹ sibẹ. Oju rẹ kekere… O n joro tobẹẹ ti oju rẹ mejeeji fi da.

73 Nigbanaa ni Satani wa si ibi ti mo wa. O ni, “Ṣebi o sọ wipe Ọlọrun daradara ni?”

Mo ni, “Bẹẹni, mo sọ bẹẹ.”

“Ṣebi o sọ wipe oluwosan ni? O dara, kinị se ti baba rẹ ku si ọwọ rẹ nibẹyẹn, ti iwọ si n pe - ẹlẹṣẹ ni - o n bẹbẹ fun ẹmi rẹ. Eeṣe ti aburo rẹ fi ku sọwọ aburo rẹ keji, nita nibẹyẹn, iwọ si wa lori pẹpẹ iwaasu, o n waasu ni ọsẹ melo kan sẹyin? O ni, ”Eeṣe ti ko fi da ọ lohun? O sọ wipe O fẹran rẹ. O gba ọ la.“

Ko lee sọ fun mi wipe ko si Ọlọrun, nitori mo ti ri i na. Ṣugbọn o n sọ fun mi wipe ko bikita fun mi.

O ni, “Iyawo rẹ ni o wa nibẹyẹn; awọn ọmọ rẹ yoo wọ ibẹ laipẹ. O ti sin baba rẹ. O ti sin aburo rẹ. Iwọ yoo sin iyawo rẹ lọla, ọmọ rẹ kekere ni o tun n ku lọ yii. Ọlọrun rere si ni. O si wipe Oluwosan ni.” O ni, “O ti sọ ara rẹ di oniyẹyẹ.”

74 Kini o ṣe? O n ṣiṣẹ lati ita, lọdọ ẹni ti akọkọ.

O ni, “Wo o bayi. Njẹ o mọ, nigbati o jẹ … ni ọdun melo kan sẹyin, ni bii ọdun meji tabi mẹta sẹyin, ki o to gba nkan yii, awọn eniyan bọwọ fun ọ. O n gbe igbe-aye ti o dara, ti ó si mọ́. Gbogbo ọmọbinrin laarin ilu ti o ba fẹ ba ọkunrin jade, iwọ ni wọn yoo ba jade, nitori wọn mọ̀ wipe awọn yoo mọ́, laisi wahala.”

Mo lee duro niwaju eyikeyi ninu wọn. Emi ko bu ẹnikẹni ninu wọn ri, emi ko sọ ohunkohun ri. Ti o ba tilẹ ṣi iwa hu, emi yoo gbe e lọ si ile wọn ni.

Gbogbo eniyan ni o fẹran rẹ, ṣugbọn kini o jẹ bayi? Gbawere-mẹsin lasan.“

Bẹẹ ni. Bẹẹ ni mo jẹ. Awọn nkan wọnyi n ko ara wọn jọ. Ero ti ita, ẹmi si n ko awọn nkan wọnyi jọ. “Bẹẹ ni, Satani.”

“Lẹyin gbogbo eyi, ṣe o si sọ wipe O jẹ oluwosan?”

“Bẹẹni, bẹẹni.”

“O n bẹbẹ, o n kigbe, awọn eniyan si n sọ fun ọ wipe ko ri bẹẹ, wipe o ti kuro loju ọna. Ijọ rẹ kọ ọ silẹ nitori nkan yii. Ijọ Onitẹbọmi rẹ ti o wa nibẹyẹn, wọn le ọ sita nitori nkan yii.”

“Bẹẹni.”

“O sin baba rẹ. o sin aburo rẹ. Iyawo rẹ naa wa nibẹyẹn, fun sinsin, ọmọ rẹ si niyi, ni iṣẹju mẹẹdogun si i, oun naa yoo lọ. Ṣe o ṣì jẹ oluwosan sibẹ? Ẹran-ara rẹ ati ẹjẹ rẹ, ọrọ kanṣoṣo lati ẹnu Rẹ yoo gba ẹmi ọmọ naa la. O sọ pe, 'Oluwosan ni Oun.' Awọn eniyan gbiyanju lati sọ fun ọ. Oniwaasu sọ fun ọ wipe o ti ba ara

rẹ jẹ, o ti ya were. Iwọ yoo di gbawere-mẹsin, o si sọ wipe Ó fẹran rẹ. Ṣe O fẹran rẹ nitootọ?

75 “O sọkun nitori baba rẹ. O n gbaawẹ ni alaalẹ; ni ọsan, o nilati gbadura ki o to lee gun opo ti o fi n ṣiṣẹ; Ó si jẹ ki o ku si ọwọ rẹ gẹgẹbi ẹlẹṣẹ. Iyawo rẹ nkọ… Obinrin arẹwa ni, iwọ si fẹran rẹ.” (Iya Billy niyẹn - ọpọlọpọ yin ni o ranti Hope.) “Arẹwa obinrin ni. Inu yin si dun; ile yin kekere wa nibẹyẹn, pẹlu awọn aga ati tabili ti iye owo rẹ to dọla meje tabi mẹjọ. Iwọnba aga ati tabili ti ẹ ni niyẹn, ṣugbọn sibẹ, o fẹran rẹ; ẹ fẹran ara yin. O si lọ n gbadura fun awọn ẹlomiran - awọn miiran ti ori wọn ti daru - wọn yoo dide, wọn yoo si ba tiwọn lọ, wọn n wipe ara awọn ti da. Ṣugbọn iyawo tirẹ bayi… Oun niyẹn, ọjọ keji ti o ti ku niyi. O wa ni ile igbokupamọ si, lọdọ Scott and Combs. Oluwosan si ni, tabi bẹẹkọ? Ọmọkunrin rẹ kekere naa ti wa loju iku, Billy Paul, ọmọ oṣu mejidinlogun. Ọmọbinrin rẹ kekere, ọmọ oṣu mẹjọ ni o wa nibẹyẹn, oun naa n ku lọ lọwọ aisan ọpọlọ ati ọpa ẹyin, o gbadura, Ọlọrun si fa aṣọ iboju kan wa si ilẹ, wipe, 'Pa ẹnu mọ; emi ko gbọ … emi ki yoo gbọ tirẹ rara.' Ó kọ ẹyin Rẹ si ọ. O si sọ wipe Ọlọrun rere ni, abi? Ó fẹran rẹ! Gbogbo awọn ọmọbinrin ti o ba rin ri, gbogbo awọn ọmọkunrin ti o ba rin ri, awọn ọrẹ rẹ ti o dara ju, gbogbo wọn ti kuro lọdọ rẹ, nitoriti o jẹ gbawere-mẹsin.”

76 Ohun gbogbo ti o n sọ fun mi, otitọ ni. Bẹẹ ni ohun gbogbo ti o n sọ ri. Ṣe o ye yin, ninu ara yii? Ni akoko naa, mo ti fẹ sọ pe, “Ti o ba jẹ wipe bi yoo ti ṣe niyẹn, a jẹ wipe emi ki yoo sin-in mọ.” Bi mọ se sọ bẹẹ, nkankan wa lati ibomiran. Ni inu mi lọhun, mo wipe, “Ta tilẹ ni iwọ funra rẹ lati ilẹ wa? Oluwa fi funni, Oluwa si gba lọ.”

Ṣe ẹ mọ, ẹni ti inu niyẹn. Kii lo ero ọpọlọ rara. Mo pada wo ẹyin, mo si ronu pe, “Bawo ni mọ se de ori ilẹ aye. Ọdọ awọn ọmuti ni mo gba wa si aye. Bawo ni mo ṣe de ihin? Tani o fun mi ni iye mi? Tani o fun mi ni iyawo yẹn? Tani o fun mi ni ọmọ yẹn? Nibo ni iyawo mi ti wa? Nibo ni iye mi ti wa?

Mo ni, “Bi O tilẹ pa mi, sibẹ, emi yoo gbẹkẹ le e.” Mo ni, “Pada lẹyin mi, Satani.”

77 Mo gbe ọwọ mi le ọmọ naa. Mo ni, “Sharon, Olufẹ, emi yoo gbe ọ si ọwọ iya rẹ ni iṣẹju melo kan si asiko yii, awọn angẹli Ọlọrun yoo si wa mu ọ lọ. Ṣugbọn Baba rẹ yoo tun ri ọ lọjọ kan. Emi ko mọ bi yoo ti ṣe ri, Olufẹ. Emi ko lee sọ fun ọ bi yoo ṣe ri, nigbati O kọ ẹyin Rẹ si mi, ti ko gbọ adura mi fun ọ.” O jẹ ki iyawo mi ku, pẹlu bi mo ṣe di ọwọ rẹ mu, ti mo n sọkun nitori tirẹ. Ọwọ mi ni baba mi ku si pẹlu, o n wo mi, o n gbiyanju lati mi. Mo si gbadura kikankikan. Bawo ni mo ṣe lee dojukọ awọn eniyan, ki n si tun maa waasu iwosan atọrunwa. Bawo ni mo ṣe lee waasu wipe Ọlọrun rere ni, ti O si jẹ ki baba mi ku gẹgẹbi ẹlẹṣẹ. Bawo ni mo ṣe lee waasu iyẹn? Emi ko mọ, ṣugbọn mo mọ wipe Oun tọna.

78 Ọrọ Ọlọrun ko lee kuna laelae. Yoo bori laibikita ohun ti o ṣẹlẹ. Nigbanaa ni mo mọ wipe nkankan wa ninu gbogbo ero, ninu gbogbo ijilara, ati ohun gbogbo bẹẹ. Ẹni ti inu kan wa ti o duro ni wakati yẹn, ko si ohun miiran ti o lee ṣe e. Gbogbo ero ọpọlọ - ohun gbogbo ti a lee fihan, ohun gbogbo lee fihan wipe ó kuna, emi naa si kuna; ṣugbọn Ọrọ Ọlọrun ti a ti yan tẹlẹ ṣaaju ipilẹṣẹ aye ni o di mi mu ni inu lọhun.

Mo ni imọlara wipe afẹfẹ kan wọ inu ile naa. Ẹmi rẹ si lọ sọdọ Ọlọrun.

79 Arakunrin, Arabinrin, jẹ ki n sọ fun ọ wipe, ohun kanṣoṣo ti o wa niyẹn. Maṣe gbiyanju lati fi ọgbọn ori gbe e. Maṣe gbiyanju lati ni irun gigun nitoripe mo sọ bẹẹ. Maṣe gbiyanju lati ṣe awọn nkan wọnyi nitori ninu ara rẹ… Maṣe gbiyanju lati ṣe e, ki o le ba awọn ẹlomiran dọgba, ṣugbọn iwọ duro niwaju Oluwa titi ti nkankan ni inu lọhun…

Ọpọlọpọ yin ro wipe nitoriti ẹ ni irun gigun, iyẹn tumọ si wipe ẹ o lọ si ọrun. Ko tumọ si iyẹn o. Ọpọlọpọ wọn ni o ro wipe, nitoriti awọn jẹ obinrin oniwa rere, wọn yoo lọ si… Ko tumọ si iyẹn.

80 Ọpọlọpọ wọn ro wipe nitoriti ijọ awọn wa ninu ẹgbẹ kan, ẹgbẹ nla kan, ti awọn ọmọwe nipa ẹsin wà… Ko tumọ si iyẹn. Ọpọ ro wipe nitoriti awọn fedefọ, awọn ti ni Ẹmi Mimọ. Ko tumọ si iyẹn, bi o tilẹ jẹ wipe Ẹmi Mimọ maa n fedefọ. Ṣugbọn o di igba ti ojulowo Ẹmi Mimọ ni inu rẹ ba tẹle gbogbo Ọrọ…

Ti Ẹmi Mimọ ti o wa ninu rẹ ba mu ọ fedefọ, ti o si boju wọ ẹyin,

ti ko si gba gbogbo Ọrọ ti o ku, a jẹ wipe ẹmi odi ni. O nilati wa lati inu, eyiti iṣe Ọrọ naa lati atetekọṣe. Ni ibẹrẹ iṣẹda Ọlọrun, nigbati Ọlọrun bẹrẹ lati maa da ẹda, O mu ki o wa… Wo o, o bẹrẹ ni ibẹyẹn gẹgẹbi iru, titi ti o fi de ibi ti o wa bayi, ẹ si wa ninu Kristi. Nigbati Kristi ku, O ku lati ra gbogbo yin pada. Ẹ si jẹ ara Ọrọ yii. Bawo ni Bibeli, ani gbogbo rẹ - “ẹsẹ lori ẹsẹ; ila lori ila … diẹ nihin, diẹ lohun.” Eyiti o kere ju ninu rẹ ki yoo kuna. Bawo ni iwọ ti o jẹ ara Ọrọ yẹn ṣe lee tako awọn ti o ku rẹ, tabi eyikeyi ninu rẹ?

81 Ki Ọlọrun bukun fun yin. Mo ti lo kọja akoko bayi. Emi ko ni i lọkan lati ṣe eyi, lati da yin duro pẹ to bẹyẹn. Ẹ ma binu wipe mo da yin duro; n ko tọrọ aforiji fun ohun ti mo sọ o. A ti wa ni opin nkankan, ẹyin ọrẹ.

Mo lero wipe gbogbo ẹyin ti ẹ wa nibi yii ni ẹ jẹ ọmọ ijọ yii. Emi kii gbe ile to lati mọ awọn ti o jẹ ọmọ ijọ

yii. Mo lero wipe gbogbo yin ni ẹ maa n wa sibi yii deedee.

Ẹ jẹ ki n sọ nkankan ti ọ sẹlẹ fun yin. Ṣe ẹ lee fun mi ni iṣẹju mẹfa si i?

82 Ṣe Ẹni-ọwọ, Ọgbẹni Orland Walker niyẹn, lati Oregon, ti o wa nibi ni ọjọ Sunday ti mo wa nibi? Njẹ ẹnikẹni mọ nipa ohun nla ti o ṣajeji yii? Mo wa si ile. Ọpọlọpọ awọn eniyan ni o wa ni - ọpọ ifọrọwanilẹnuwo ni o ti wa nilẹ fun mi latị se - gbogbo wọn ni o si yẹ: awọn ọmọ wọn ti o ti ṣe igbeyawo, awọn ọmuti, ati oriṣiriṣi awọn nkan, awọn nkan ti o yẹ. Gbogbo wọn ni o yẹ ki a ri. Emi ko leẹ se gbogbo rẹ. Mo fi yin le Ọlọrun lọwọ, mo si gbe ọwọ mi le wọn ninu adura.

Ọlọrun o, emi ko lee ṣe e. Tọ wọn lọ, Oluwa. O mọ bi O ti lee ṣe e. Mo gbadura fun olukuluku wọn.

83 Billy pe mi, mo si ṣẹṣẹ de ni, pẹlu Arakunrin Banks. O ni, "Baba mi, iwọ…" Mo n ri i ti awọn eniyan n wa ọkọ ni ita, igbamiran loju titi ti o ya si ọdọ mi, wọn yoo wo ọdọ mi; emi naa yoo wo ita, n o si ju ọwọ si wọn, wọn yoo si fẹrẹ yi oju pada. Emi ko fẹ ki ẹ se bẹẹ.

Ni ijelo, nigbati wọn fẹ ra ibẹyẹn fun mi ni Tucson lati maa gbe ibẹ, Arakunrin Tony ni ibikan nibẹyẹn ti o fẹ ra fun mi ni ilọpo mẹta tabi mẹrin iye owo eleyi. Oun funra rẹ tilẹ fẹ na ọpọlọpọ owo dọla si i, ṣugbọn ọna kanṣoṣo ti o fi lee de ibẹ… Aṣọ́bodè kan duro si ita nibẹ. Ohun nla kan … afikun ni iyẹn jẹ nibẹ, ṣugbọn ẹnikẹni ninu awọn eniyan ti o n gbe ibẹ, o nilati kọ iwe lati gba aaye ki o to lee ri wọn. Aṣọ́bodè yii yoo si pe ọ, ti wọn ba fẹ ki o wọle.

Mo ni, "ṣe ẹ lee ro iyẹn nipa mi? Awọn arakunrin ati arabinrin mi, ti wọn fẹ wa ri mi, ti wọn fẹ bọ mi lọwọ, ki wọn si sọ wipe ki Ọlọrun bukun fun mi. Ṣe o ro wipe mo lee gbe ibẹyẹn, Tony?"

O ni, "Ko buru, o nilati…"

Mo ni, "Tony, bi awọn ijọ ati awọn eniyan ṣe maa n sọ wipe ki awọn eniyan maṣe wa…"

Mo ni, "Iyẹn wa fun awọn eniyan ti o ni ohun gbogbo ti wọn fẹ ki n se." Wọn yoo wipe, "O dara, Oluwa sọ fun mi… Halleluyah! Emi yoo duro sibi yii! Ogo ni fun Ọlọrun! Oluwa sọ fun mi wipe o nilati ṣe ipade ninu ẹgbẹ wa nibi yii, bẹẹni sà. Ogo ni fun Ọlọrun! Ọlọrun sọ bẹẹ fun mi. Ti o ko ba ṣe e, Arakunrin Branham, o ti pada sẹyin niyẹn," ti mo si wa nibẹ, ti mo n gbiyanju latị se aṣaro, ṣe ẹ ri i. Iyẹn si ni ohun ti… Ọpọlọpọ awọn eniyan rere ni ki yoo ri aaye lati wọle nitori iyẹn.

84 Gẹgẹbi ọkunrin kan ti o fẹ lọ sọdẹ ninu oko kan. Agbẹ kan sọ pe, "Maa bọ. O lee sọdẹ." Ki o wa de ibẹ, ki o si yan ibọn si ọkan ninu awọn maaluu rẹ. Boya okete kan sa si abẹ maaluu, o si yan ibọn si okete naa lọnakọna. O tun gun ọgba rẹ̀, dipo ki o lọ si ẹnu ọna, ki o si wọle, gẹgẹbi o ti yẹ fun ọmọluabi lati ṣe; o wa gun ọgba rẹ, o si wo o palẹ. Ki o wa sọ wipe, "Emi yoo gbe iwe ikilọ si ibẹ!" Emi ko da a lẹbi rara - n ko da a lẹbi rara. Ṣugbọn kini ọ se? Ko ni jẹ ki ọdẹ ti o jẹ ọmọluabi ri aaye wọle. Bi o ṣe maa n ri niyẹn. Awọn ẹni buburu ni kii jẹ ki ẹni rere ni ipo ti o tayọ. Bẹẹni nigbagbogbo.

85 Ṣugbọn awọn eniyan wọnyẹn jẹ… Ẹgbẹẹgbẹrun awọn eniyan ni o ṣe alaini, ti wọn jẹ eniyan rere, awọn ti o ni ifẹ, ti wọn si kun fun oore-ọfẹ Ọlọrun.

Ni bayi, a ni eyi … awọn eniyan wọnyi maa n wa bẹyẹn. A ko fẹ iyẹn, rara. Ṣugbọn ọkunrin yii wa. Billy wipe, "Baba mi, sare lọ si isalẹ bayi, ni kiakia." O ni, "Iyaafin Waldrop wa nibẹ pẹlu awọn eniyan kan ti o n ku lọ. O gbọdọ ri wọn lẹsẹkẹsẹ." Mo sare wọle, mo sọkalẹ lọ sibẹ; nigbati mo n pada bọ, wọn ni, "Ko si ẹnikẹni nibi yii bikọse ọkunrin kan ti o sun si ẹgbẹ .. ita nibẹyẹn, si ori irọri ni ojoojumọ, ni ẹgbẹ ile." Wọn ni, "O sọ wipe oun fẹ ki o gbadura fun oun."

Mo ni, "O dara." O ni, "Emi yoo mu u wọle." Mo wọle wa. Mo ro wipe ọkọ ayọkẹlẹ Cadillac kan wa lẹyin ibẹ, tabi ọkọ nla kan, emi si wa ọkọ wọ ile. Ọkunrin naa wipe, "Bawo ni o." Ko mọ mi, emi wọle, pẹlu Arabinrin Waldrop, ti o ti di arugbo, oun naa wọle. Njẹ ẹ mọ, oun jẹ… Ẹ mọ nipa ọrọ rẹ, tabi bẹẹkọ? O ni arun jẹjẹrẹ; o ku lori ila adura ni nkan bii wakati kan ki n to de ọdọ rẹ, dokita rẹ si wa, ọ se afihan… Iyẹn ti to bii ọdun mejidinlogun sẹyin - arun jẹjẹrẹ inu ọkan, ṣe o ye yin. O si wa laaye loni. Arkansas ni o n gbe bayi, Phoenix ni o wa ni igba yẹn, o wipe, "Arakunrin Willie, mo korira lati wọle wa bi eleyi," o ni, "ṣugbọn emi ko ni ibi ti mo lee de si. Mo korira… Wọn ni obinrin yii yoo ku, Arakunrin Willie." O ni, "Mo fẹ mu ọrẹ kekere kan wa fun ọ, Arakunrin Willie," o ni, "ṣugbọn n ko leẹ se e, ṣugbọn mo fi ounjẹ aladidun kan sinu agolo."

86 Ah!

Nigbati mo lọ sibẹ, ti mo si ri awọn igo ounjẹ aladidun ti o gbe sibẹ, o ti mọ́ ju loju mi ju ohun ti mo lee jẹ lọ. Obinrin arugbo yẹn, bii aadọrin ọdun. Mo ni, "Arabinrin Hattie…" Emi ko lee sọ wipe "rara."

Rara o, Jesu ri obinrin opo yẹn ti o fi kọbọ mẹta sibẹ, O si fi i silẹ, se ẹ ri i. Rara. Ọlọrun yoo san ẹsan rẹ

fun-un. Oluwa wo obinrin naa san, o wo ohun gbogbo ti o ni san; o fihan oluṣọ-aguntan rẹ, ohun ti o ni lọkan, ati ohun ti o yẹ ki o ṣe - ati nkan miiran. Gbogbo wọn pada lọ, wọn n pariwo ni.

87 Billy sare wọle, o ni, "Baba mi, ọkunrin yẹn ti lọ. Emi ko lee…"

Mo ni, "Tani o wa ninu ọkọ ni ita nibẹyẹn?

O ni, "Ah, ẹnikan ti o wa lati Oregon ni," o ni, "o la ala kan. Mo sọ fun-un wipe emi ko lee fun-un ni ireti asan. Ọọdunrun awọn eniyan ni o wa nibi yii, ti wọn n duro. Mo ni … mo sọ fun-un wipe ki o kọ ala naa silẹ. Mo ni ọpọlọpọ awọn bẹẹ nibi yii, a o kan fi iyẹn kun-un ni."

Mo ni, "Jẹ ki o wọle wa. Fun-un ni iṣẹju marun-un."

Lẹsẹkẹsẹ ti ọkunrin naa wọle - iṣẹju marun-un! O ni, "Emi ni Ẹni-ọwọ Walker" (mo ro wipe orukọ rẹ niyẹn), lati Oregon. Mo ro wipe ijọ ẹlẹkọ-adamọ miiran ni o ti wa. Emi ko mọ - boya ijọ Alagba, Episcopalian; tabi nkankan.

O ni, "Mo ba ọ pade ni nkan bii ogun ọdun sẹyin. Mo wa si Grants Pass nibiti" … ki iṣe Grants Pass, ṣugbọn mo gbagbe orukọ ibẹ. "Nibẹ̀," o ni, "gbogbo orilẹ-ede yii … o jade ninu iwe-iroyin ni gbogbo owurọ." O ni, "Gbogbo eniyan ni o mọ nipa rẹ̀." O ni, "Emi ko tilẹ lee de inu ile ibi ti o wa, ṣugbọn mo ri ọ ti o n rin lọ loju titi lọjọ kan. Mo wa ba ọ." O ni, "Awọn ọkunrin bii mẹrin tabi marun-un wa ni ẹgbẹ rẹ, mo si bọ ọ lọwọ. Mo sọ fun ọ wipe emi ni Arakunrin Walker, iwọ naa si sọ ẹniti o jẹ fun mi, a sọ ọrọ diẹ, awọn ọkunrin mẹta tabi mẹrin kan ti o wa pẹlu rẹ si n ti ọ lọ." O ni, "Emi ki iṣe alatako rẹ, emi ko si wa fun ọ." O ni, "Ko kan ye mi ni."

88 O ni, "Ó n lọ bẹẹ fun ọdun melo kan, lẹyin igba diẹ, ọkunrin kan sọ fun mi wipe ki n wa feti si awọn fanran kan ni nkan bii ọdun mẹta sẹyin." O ni, "Ọkunrin naa ṣí awọn fanran naa, nigbati o ṣe bẹẹ," o ni, "mo gbọ ti o n sọrọ." O ni, "Ọkunrin yii gbagbọ wipe wolii ni ọ. Mo ni … Mo sọ fun ọkunrin naa wipe, 'Emi ko mọ nipa awọn nkan wọnyẹn - ó lee jẹ bẹẹ, ohun ti mo mọ niyẹn.'"

O tun wipe, "Lẹyinnaa, ọkunrin miiran kó wá sinu ilu wa, o wa ṣe ipade kan. Mo lọ ba a, o si wipe, 'Emi ni wolii Ọlọrun fun ọjọ oni.'" O ni, "Ẹyin melo gan-an ni ẹ wa?" O ni, "Mo gbọ ibiti ọkunrin kan ti n feti si awọn fanran nibi yii, ti o sọ wipe William Branham ti o wa ni ila-oorun, oun ni wolii ọjọ oni, ati iru awọn nkan bẹyẹn."

O ni, "Ọkunrin yii … [emi ki yoo sọ orukọ rẹ nitori ko tọ, ṣe o ye yin?] O ni, 'Mo mọ William Branham.' O ni, 'Ṣugbọn ẹkọ-eke ni ẹkọ rẹ.' O ni, 'Oun kii ṣe ọmọ ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ, ko gbagbọ ninu ẹri akọkọ.' O ni, 'Ohun miiran niyi,' o ni, 'ọrọ awọn wolii agba ati awọn wolii kekere yii - ko si ohun ti o n jẹ bẹẹ.' O ni, "Yala ki o jẹ wolii, tabi o kii ṣe wolii, ko ju bẹẹ lọ.'"

89 O ni, "Ko buru, Ọgbẹni, emi ko ba ọ jiyan nipa rẹ, mo kan sọ wipe mo gbọ ti ọkunrin yii wipe ọkunrin William Brahanm yii jẹ … ọkunrin yii sọ wipe wolii ni." O ni, "O n ya mi lẹnu wipe awọn melo ni o wa. O ni, 'Ṣugbọn mo fẹ ki o mọ eyi. Emi ni wolii iran yii.'"

O ni, ̣"se iwọ ni? Ki Oluwa bukun fun ọ, ki O si wa pẹlu rẹ."

O tẹsiwaju, ko tilẹ kọbi ara si i. O ni oun bẹrẹ ipade bii mẹta tabi mẹrin kan laarin awọn ara oun. O lọ si Ile Ifiweranṣẹ, o si wipe, "Ẹ maṣe paarọ awọn iwe mi. Ẹ fi i silẹ sibi yii titi ti emi yoo fi pada de lẹyin bii ọjọ mẹrin tabi marun-un, ṣe ẹ gbọ?" Wọn ni … o fi iwe kan sibẹ wipe ki wọn maṣe yi i pada. O lọ ri ọmọbinrin rẹ. Loju ọna, o duro ninu ijọ kan, o si ṣe ipade alẹ ọjọ yẹn nibẹ. Ni owurọ ọjọ keji, o ni oun ronu wipe, "Lọ ko awọn lẹta rẹ," nigbati o si ṣe bẹẹ, lẹta kan ti wọ inu apoti ifiweranṣẹ rẹ, o si ti de ọwọ ọmọbinrin rẹ. Ọmọbinrin rẹ ni o fi awọn iwe naa ranṣẹ.

90 O ṣí i, o ni ọkunrin kan ni o kọ iwe naa. Ọgbẹni Hilderbrandt, ẹniti o jẹ ọrẹ mi, ẹniti o ti n mu ki awọn eniyan gbọ awọn fanran naa. O ni Ọgbẹni Hilderbrandt gbọ ọrọ kan lati ọdọ Roy Borders (ọkan ninu awọn alabojuto ipade mi niyẹn, ṣe ẹ mọ) o sọ wipe emi yoo ṣe ipade kan ni ibi yii, lati ọjọ kejidinlọgbọn titi de ọjọ kinni. O ni oun pada wa lati ri i funra oun. O ni, "Wo o bayi. Awọn eniyan wọnyẹn n gbiyanju lati fa mi wọ inu nkankan bẹyẹn," ṣe ẹ ri i. O kan sọ lẹta naa sinu idọti ni, o si tẹsiwaju bẹẹ.

O lọ ṣe ipade ni alẹ ọjọ yẹn, ni owurọ ọjọ keji… O wa bẹrẹ si sọkun ninu ọkan rẹ, ninu iyara nibẹ.

91 O ni, "Ọgbẹni Branham, mo mọ wipe mo nilati duro niwaju Ọlọrun." O ni, "Emi ko mọ boya mo sun ni o, tabi ohun ti o ṣẹlẹ." O ni, "Mo la ala… Emi yoo sọ wipe mo sun, mo si la ala." O ni, "Mo ro wipe ọmọkunrin mi ki ọwọ rẹ bọ inu apo kan ni ọja." O ni, "Nigbati o ṣe bẹẹ, apo eso apple ni, gbogbo rẹ si danu. Nigbati mo lọ lati sa wọn, gbogbo rẹ jẹ eso apple ti koi tii pọn, a si ti ge wọn jẹ." O ni, "Mo n sa wọn, mo n ko wọn pada sinu apo yẹn." O ni, "Awọn kan ninu wọn yi jade, wọn si yi lọ si isalẹ. Mo gbiyanju lati lọ ko wọn kuro lori koriko," o ni, "wọn si yi si abẹ ọkan ninu awọn ọgba ti wọn ti ilẹkun mọ, títì nla kan si wa nibẹ. Mo pada wo ila-oorun," o ni, "a so ẹwọn naa mọ apata nla kan ni ila-oorun. Mo pada lọ sibẹ; mo ro wipe emi yoo sọ ẹwọn yii

kalẹ, ki n si lọ ko awọn eso apple naa fun ọkunrin yẹn." O ni, "Mo bẹrẹ si fa ẹwọn naa wa silẹ."

92 O ni, "Ohùn kan mi gbogbo ilẹ." O ni, "Ilẹ mi titi labẹ ẹsẹ mi."

O ni, "Lẹyin ti mimi naa dawọ duro, mo gbọ ohùn kan." O ni, "Arakunrin Branham, ohùn rẹ ni. Mo mọ, nkankan sọ bẹẹ fun mi." O ni, "O sọ pe, 'Emi yoo gun ẹṣin ni ọna yii lẹẹkan si i.'" O ni, "Mo bẹrẹ si wo apata naa ni oke bi eyi, mo n wo o, titi ti o fi kọja awọn ikuuku, o si wà ni oke apata kan ti o lọ lati ila-oorun de iwọ-oorun, pẹlu ori ṣonṣo bi ile olori-ṣonṣo kan. Mo sare pada wa si ila-oorun," o ni, "iwọ wa nibẹ, lori ẹṣin kan ti o jẹ wipe… Emi ko ri iru rẹ ni gbogbo ọjọ aye mi: ẹṣin funfun nla kan ni, irun funfun ọrun rẹ ṣàn wa silẹ." O ni, "O wọ aṣọ bii Ijoye India, pẹlu gbogbo ohun ti awọn India maa n lo." O ni, "O ni igbaya, awọn ifunpa ni ọrun ọwọ, titi walẹ bẹẹ." O ni, "O gbe ọwọ rẹ soke." O ni, "Ẹṣin yẹn duro sibẹ bii ẹṣin jagunjagun, pẹlu igbesẹ rẹ ti o ga, bi o ṣe n rin, emi si duro jẹẹ. O ni, "O fa ijanu ẹṣin naa, o si n gun ẹṣin naa lọ si iwọ-oorun."

93 O ni, "Mo wo isalẹ, ọpọlọpọ awọn onimọ-ijinlẹ si wa nibẹ."

Ni owurọ ọjọ keji (iyẹn jẹ Satide) … ni owurọ ọjọ keji, mo waasu lori wipe imọ-ijinlẹ jẹ ti eṣu, ṣe ẹ mọ.

O ni, "Awọn onimọ-ijinlẹ, wọn n da awọn nkankan sinu awọn igo, wọn si n po wọn papọ." O ni, "O dá ẹṣin naa duro, o gbe ọwọ rẹ soke, o si bẹrẹ si pariwo, 'Emi yoo gun ẹṣin ni ọna yii lẹẹkan si i.'" O ni, "Gbogbo ilẹ mi titi. Awọn eniyan wọnyẹn naa mi titi"; o ni, "wọn wo ara wọn loju, wọn gboju soke wo ọ, wọn sọ ejika, wọn si tẹsiwaju pẹlu iwadi imọ-ijinlẹ wọn."

O ni, "O bẹrẹ si lọ si iha iwọ-oorun, nigbati iyẹn sẹlẹ," o ni, "mo ri ọkunrin ti o pe ara rẹ ni wolii yii, se ẹ mọ. O gun ẹṣin kan wá, eyiti o ni àwọ̀ funfun ati dudu papọ." O ni, "Ó wá si ẹyin ẹṣin nla yii." O ni, "O ga kọja awọn ikuuku, bẹẹni oju ọna naa ko fẹ." O ni, "Ẹṣin naa, pẹlu bi afẹfẹ ṣe n fẹ awọn iyẹ ati ohun gbogbo ti o wa lara agbada rẹ," o ni, "irun ọrun ẹṣin naa, ati iru rẹ ni afẹfẹ n fẹ. Ẹṣin nla kan ni, o n rin bi o ti tọ́." O ni, "Ọkunrin yii sare wa si ẹyin rẹ, ọna Canada ni o gba wa [Canada ni ọkunrin naa n gbe.]" O ni, "O pada wa," o ni, "O mu ẹṣin rẹ̀ kekere, o si n gbiyanju lati bi ẹṣin nla tirẹ ṣubu, ó yi oju rẹ̀ pada, ó si n fi itan rẹ̀ lu… O ni, "Ko tilẹ mi ẹṣin nla naa rara; o kan n rin lọ ni tirẹ ni." O ni, "Lojiji," o ni, "o yiju pada. Iyẹn ni igba kẹta ti iwọ yoo sọrọ, ṣugbọn igba keji ti o wipe, 'Emi yoo gun ẹṣin.'" O si wipe, "O ko sọrọ bi ọ se sọrọ tẹlẹ; o paṣẹ ni." O ni, "O yiju pada, o si pe orukọ ọkunrin naa, o wipe, 'Kuro nibi. O mọ wipe ko si ẹniti o lee gun ẹṣin ni ọna yii lai jẹ wipe Ọlọrun yan-an lati ṣe bẹẹ. Kuro nibi."

94 O ni, "Ọkunrin naa yiju pada"; o ni, "ọkunrin naa ti kọ awọn iwe si mi ri. Nibi itan ẹṣin rẹ [awọ dudu ati awọ eeru ti o da papọ yẹn]…" O ni, "A kọ orukọ rẹ̀ sara itan ẹṣin rẹ̀ - orukọ rẹ bi o ṣe maa n kọ ọ sinu iwe rẹ. O gun ẹṣin naa lọ si iha ariwa.

O ni, "Lẹyinnaa, o sọkalẹ lọ; ẹṣin nla yẹn yiju pada, o si lọ jinna réré si iha iwọ-oorun." O ni, "O duro, o na ọwọ rẹ soke bẹyẹn." O si bẹrẹ si sọkun. O ni, "Arakunrin Branham, ṣe o ri ẹṣin ti o duro si ibẹyẹn, ṣe o ri ohun ija ogun yẹn ati ohun gbogbo bẹyẹn, ati igbaya yẹn, ati ohun gbogbo ti o n tan yinrinyinrin." O ni, "O gbe ọwọ rẹ soke fun igba diẹ; o si tun wo o, o mu ijanu ẹṣin naa, o wipe, 'Emi yoo gun ẹṣin kọja nibi yii lẹẹkan si i.'" "Gbogbo ilẹ mi titi, siwa ati sẹyin, ko si si iye ninu mi mọ. Mo ṣubu si ẹgbẹ apata naa, mo si taji." 92:35

O ni, "Kini itumọ iyẹn, sà?"

Mo ni, "Emi ko mọ."

95 Ni owurọ ọjọ keji, Junior Jackson, ẹniti o la ala nipa ile olori-ṣonṣo naa, se ẹ mọ, nigbati mo lọ si iwọ-oorun - se ẹ ranti iyẹn; o pe mi ni bii oṣu kan tabi meji ṣaaju igba yẹn. O la ala kan ti o n jo o lọkan; o nilati sọ fun mi. Mo ni, "Billy… Awọn eniyan bii ogun ni o wa nibẹ." O ni, "Junior Jackson sọ wipe oun nilati rọ́ ala yẹn fun ọ."

Mo ni, "Jẹ ki o wọle fun iṣẹju marun-un."

O mu iyawo rẹ wọle, o ni "lati jẹri." O ni, "Mo la ala kan, Arakunrin Branham, emi ati iyawo mi n wa ọkọ lọ ni ita. Mo pada wo iha ila-oorun, mo si ri - o dabi ohun tintin kan, bii ọkan ninu awọn àwo ti o n fo."

96 Ẹ wo o, aye ko mọ ohun ti o jẹ. Ṣe ẹ mọ … ṣe ẹ mọ; awa mọ ohun ti o jẹ. A mọ wipe awọn angẹli idajọ ti o n ṣe ayẹwo ni, ṣe o ye yin. Ile-iṣẹ ologun America (Pentagon), wọn n fi ọgbọn-ori se iwadi; awọn nkan yẹn yoo poora bii manamana; wọn yoo si kuro lọna fun ohun gbogbo ti wọn n lò. Wọn ko mọ ohun ti o jẹ. Ẹ jẹ ki wọn ro ohun ti o ba wu wọn lati ro. Wọn n pe wọn ni àwo ti o n fo tabi ohunkohun; ko ye wọn.

97 O ni, "Mo ri i ti o n bọ, mo si n wo o. Ọkunrin kan ni, lori ẹṣin." O ni, "O n sare bọ bii manamana." O ni, "Mo ri i wipe o fẹ sọkalẹ wa si iwaju mi, mo da ọkọ mi duro, mo fo jade. Nigbati mo ṣe bẹẹ, ẹṣin kan duro si oju ọna, ẹṣin jagunjagun nla kan ni, o funfun, o n rin lọ pẹlu igbesẹ giga." Ọrọ naa niyẹn, ṣe ẹ mọ, o n yan lọ.

O ni, “Ọkunrin kan joko sori rẹ. O wọ aṣọ awọn ara iwọ-oorun; kii ṣe darandaran o, ṣugbọn,” o ni, “o dabi olori awọn darandaran tabi nkankan. [ṣe ẹ ri i, gbogbo aṣẹ rẹ gẹgẹbi ijoye lati iwọ-oorun. Awọn India lori awọn India, awọn darandaran lori…]” ṣe o ye yin? o ni, “Ọkunrin naa fa fila rẹ wa si isalẹ, o si n wo ẹgbẹ kan.” O ni, “Nigbati o kọju si ẹgbẹ keji,” o ni, “iwọ ni, Arakunrin Branham.” O ni, “O ko sọrọ bi o ṣe maa n sọrọ. O sọ pe, 'Junior' - mo pe e ni igba mẹta. O ni, 'Emi yoo sọ ohun ti o nilatị se fun ọ.'” O ni, “Lẹyin eyi, o fa ijanu ẹṣin naa; ó yipo lẹẹmẹta, o si fo lọ soke ọrun, bi ọ̣ se lọ niyẹn, si iha iwọ-oorun.

98 O ni, “Duro na. Mo wo ayika, ẹṣin kekere kan si wá, ti o kere si iyẹn, ṣugbọn irú ẹṣin kannaa ni, o kan kere ni; o duro.” O ni, “Mo rin kaakiri.” O ni, “O nilati jẹ wipe o fi eleyi ranṣẹ si mi ni. Mo joko sori rẹ. [Junior naa ti gun ẹṣin diẹ pẹlu.]” O ni, “O mọ bi ijoko rẹ ṣe ba ọ mu, Arakunrin Branham, awọn ijoko naa ati ohun gbogbo.” O ni, “Mo ronu pe, 'O dara, eyi naa ti dara to fun mi.' Mo fa ijanu rẹ; mo si rin lọ si ofuurufu.” O ni, “Mo fa ijanu rẹ, mo si da a duro, mo yi oju rẹ pada, mo si pada. Nigbati mo pada,” o ni, “mo da ẹṣin naa duro, mo sọkalẹ, mo si ba iyawo mi sọrọ, ẹṣin naa si lọ.” Ara rẹ ko balẹ.

99 Ni ijẹta, tabi ijẹrin, Leo Mercia naa wa, oun naa wa pẹlu iru ala kannaa, ko si mọ nipa eyi: o n gbiyanju lati sọ akọ ẹsin nla funfun kan di akọ ẹsin dudu, wọn ko si lee ṣe e. Ara rẹ ko balẹ. O ni, “Mo lọ sibẹ; o ni 'Leo,'” o sọ ohun ti mọ̣ se fun-un. (Emi ko fẹ sọ ọ nibi yii, ṣe o ye yin.) Mo sọ ohun ti mo ṣe fun-un. O ni, “ṣe ko ye ọ ni? Ki iṣe lati mọ eyi…” Emi ko mọ wipe Ed Daulton ni ọmọkunrin kan ti o jẹ ana rẹ, ana rẹ yii si ni aja kan ti o n jẹ orukọ yii.

“'Iwọ yoo mọ ala rẹ yẹn, Leo, ṣugbọn nigbati o ba ji, ranti rẹ̀!'” O ni, “Emi ko gbọ iru aṣẹ bẹẹ ri.”

100 Ni akoko yẹn ni Roy Roberson naa wọle wa, o ni, “Arakunrin Branham, ṣe o ranti igba yẹn, ki o to fi ijọ silẹ ni igba akọkọ? Mo ri ọ ti o joko, bi ẹnipe ni Palestini. Awa n … gbogbo igbimọ ijọ ati ohun gbogbo, o dabi ẹni wipe a joko sibi tabili Ounjẹ Alẹ Oluwa, iwọ si sọrọ, ohun ti o n sọ ko si da ọ loju.” O ni, “Ikuuku funfun kan wá, o si gbe ọ, o gbe ọ lọ.”

Ẹni melo ni o ranti ala Arakunrin Roy? O ni, “Ikuuku funfun naa gbe ọ lọ,” o ni, “o lọ, emi si n lọ kaakiri oju titi, mo n kigbe, mo si n sọkun; nigbati mo jade wa sibi yii, ti ọwọ yẹn si rọ bi ẹni pe … idi niyẹn ti ó fi ju ọkọ naa silẹ, ti o si bẹrẹ si sọkun nigbati o ri mi ti mo goke wa si ibẹ. Emi ko ri i tẹlẹ, ki o lee rọ ala naa fun mi. O si wipe … o n ko igbo jọ … o wipe,

101 “O lọ, mo n rin kaakiri titi nibigbogbo, mo n gbiyanju lati wa ọ ri; emi ko ri ọ nibikibi. Mo n pariwo pe, 'Arakunrin Branham, má lọ!' O ni, 'Ikuuku funfun kan wọle wa, o gbe ọ, o si gbe ọ kuro laarin wa, lọ si iha iwọ-oorun.”

Iyẹn ṣẹlẹ ṣaaju ẹkọ ile olori-ṣọnṣọ naa tabi ohunkohun. O ni, “O gbe ọ lọ si iha iwọ-oorun. Mo n kigbe, mo n rin kaakiri titi, lẹyin igba diẹ, mo lọ joko sidi tabili. Mo wa wo ibi ti tabili naa pari si.” O ni, “Mo ri i wipe apakan ara rẹ funfun bii yinyin.” O ni, “O duro sibẹ, o si sọrọ pẹlu aṣẹ. Ko si iyemeji nipa rẹ.” O ni, “Gbogbo eniyan ni ohun ti o sọ ye.”

Ah, arakunrin mi, arabinrin mi; gbogbo yin ni o mọ bayi wipe 'mo mọ ohun ti iyẹn tumọ si,' ṣe o ye yin. Ẹ ṣaa maa wo o. Ẹ sunmọ Kristi. Ẹ jẹ ki n kilọ fun yin, gẹgẹbi iranṣẹ Ihinrere, wipe eyi … maṣe gba ohunkohun ti ko tọ! Maṣe ronu ohunkohun! Iwọ ṣaa duro daradara, titi ti inu ọkan rẹ yoo fi ni idakọro pẹlu Ọrọ naa, wipe o wa ninu Kristi, nitori iyẹn nikan ni yoo… Nitori a ti wa ni igba ẹtan ti o ga julọ ti a tii gbe inu rẹ ri. Yoo tan awọn ayanfẹ gan-an jẹ, ti o ba ṣee ṣe, nitori wọn ni ami-ororo. Wọn lee ṣe ohunkohun bii ti awọn ti o ku.

102 Wẹ aye rẹ mọ, san awọn gbese rẹ, maṣe jẹ ẹnikẹni ni gbese. Jesu wipe, “Ki iṣe…” Emi ko sọrọ nipa owo ile rẹ ati awọn nkan miiran. O nilati san iyẹn. Mu ohun gbogbo kuro ni ọwọ rẹ. Ṣe ohun gbogbo lọna ti o tọ. Mura silẹ. Mura silẹ. Ẹ ranti, ni orukọ Oluwa, nkankan fẹ ṣẹlẹ!

Mo n lọ sori oke ni ọsẹ yii, ki iṣe lati ṣe ọdẹ ọkẹrẹ nikan - lootọ, mo fẹ lati ṣe ọdẹ ọkẹrẹ - ṣugbọn mo n lọ sibẹ fun idi yii, wipe, “Ah, Ọlọrun, emi ko mọ ọna ti n ba tọ, emi ko si fẹ padanu eleyi. Ran mi lọwọ.”

Ẹ gbadura fun mi. Ṣe ẹ o ṣe bẹẹ? Emi naa yoo maa gbadura fun yin. Mo ni ireti wipe, nipa aanu Ọlọrun, emi yoo ba ẹnikọọkan yin pade, a o si pade ni ilẹ ti o dara ju eyi lọ.

103 Kini a n wa sibi yii fun? Kini a n ṣe? Ṣe a n wa sibi yii lati ta ayo ni? Ṣe a n wa sibi yii lati ṣe ipade ẹgbẹ awo ni? Kristi ko lee de ayafi ti ijọ yẹn ba pe. Awa ni O n duro de. Mo gbagbọ wipe a ti wa ni igba ikẹyin.

Ẹ wo California. Ẹ wo awọn ija igboro. Ẹ wo bi wọn ṣe pa eniyan mọkandinlogun - nitori ẹyamẹya. Njẹ n ko sọ fun yin nibi yii tipẹtipẹ wipe Martin Luther King yoo ko awọn eniyan rẹ lọ sinu ipaniyan? Ẹni melo ni o ranti iyẹn? Ki iṣe awọn eniyan alawọ dudu yẹn; awọn olori wọn ni o n ru wọn soke. Ki iṣe iṣọkan, ipinya ni, tabi ohunkohun ti ẹ ba fẹ pe e. Eṣu ni! Bẹẹ ni. Kii ṣe fun awọn alawọ funfun nikan, awọn alawọ dudu pẹlu; gbogbo wọn ni. Eṣu ni!

104 Ọpọlọ awọn eniyan ti dibajẹ. Ko si ireti mọ. O ti kọja ireti. Gbogbo rẹ ti di egbo kikẹ.

Ironu awọn eniyan… Wọn ko lee ṣe ipinnu. Emi ki iṣe oloṣelu… Emi ki … iṣe ẹgbẹ oṣelu Democrat tabi Republican; ẹlẹgbin ni gbogbo wọn. Ijọba kan ni mo wa fun, iyẹn ni ijọba Jesu Kristi. Ko ju bẹẹ lọ. Ṣugbọn bawo ni… Njẹ ẹ tilẹ ri awọn fidihẹ iru eyi ti a ni nisisiyi ri? Bii awọn ara Texas ti a ni nibẹyẹn. Wọn n sọ wipe, “Ohunkohun ti awọn eniyan ba n fẹ ni. Bi wọn ba n fẹ ijọba Aparo-kan-ko-ga-ju-ọkan-lọ, a o fun wọn ni ijọba Aparo-kan-ko-ga-ju-ọkan-lọ. Bi wọn ba n fẹ iṣọkan, a o fun wọn ni iṣọkan. Bi wọn ba n fẹ ipinya, a o fun wọn ni … ohunkohun.” Awọn ọkunrin da?

Ọlọrun o, bi o ṣe ri ni pẹpẹ iwaasu naa niyẹn. Awọn ọkunrin da - awọn ọkunrin ti yoo duro lori ilana gidi bi ọkunrin? Awọn obinrin ti yoo duro lori ilana da! Ijọ ti yoo duro lori ilana da? Emi ko ni akoko fun ẹmi igbabọde ti ko duro loju kan!

Ti obinrin ba jẹ obinrin, jẹ ki o jẹ obinrin gidi. Ti ọkunrin ba jẹ ọkunrin, jẹ ki o jẹ ọkunrin gidi.

105 Ti o ba jẹ aarẹ… John Quincy Adams wa da? Abraham Lincoln wa da? - awọn ẹni ti o ni iduro. Patrick Henry wa da? O ni, “Fun mi ni ominira, tabi fun mi ni iku.” Awọn eniyan ti o duro fun ẹtọ dà? Awọn eniyan da, ti ko bẹru lati sọrọ sita, laibikita boya gbogbo aye lodi si oun, sọrọ sita fun ẹtọ, ki o si duro lori rẹ, ki o si ku fun-un?

Arnold von Winkelried wa da ninu aye yii loni? Awọn olootọ eniyan da? Awọn ọkunrin ti o ni ẹmi da? Wọn jẹ aṣeyi-sọhun, wọn si ti gan, wọn ko mọ ibi ti wọn duro si. Ọlọrun, jẹ ki n duro lori ilana ọkunrin kan gẹgẹbi oniwaasu, ani Ọrọ Jesu Kristi, nitori: “Ọrun oun aye yoo rẹkọja, ṣugbọn ki yoo kuna. Ori apata yii ni emi yoo kọ ijọ mi le. Ẹnu ọna ọrun apaadi ki yoo lee bori rẹ.” Ẹ jẹ ki a dide duro.

Ibukun ni fun okun ti o so

Ọkan wo pọ ninu ifẹ Kristẹni;

Idapọ awọn ọlọkan kannaa

Dabi ti ọrun.

Ẹ fi ọwọ so ọwọ pọ bayi.

Nigbati a ba pinya,

O maa n dun wa;

Ṣugbọn a o sọkan ninu ọkan wa,

Pẹlu ireti wipe a o tun pade.

Titi ti a o tun fi pade, titi ti a o tun fi pade,

Titi ti a o tun fi pade lẹsẹ Jesu;

Titi ti a o tun fi pade, titi ti a o tun fi pade,

Ki Ọlọrun wa pẹlu yin titi ti a o tun fi pade!

106 Ẹ jẹ ki a tẹriba bayi, nigbati Arakunrin Neville yoo gbadura fun wa lati maa lọ si ile. Ẹ pada wa ni aṣalẹ yii. A ni ireti wipe a o ni isin nla ni aṣalẹ yii, ninu ile-ijọsin nibi. Ki Ọlọrun bukun fun yin, ẹ maa gbadura fun mi; emi naa yoo maa gbadura fun yin. Ẹ maṣe ro wipe gbawere-mẹsin ni mi, ẹyin ọrẹ. Ẹ maṣe ro wipe mo n gbiyanju lati fi nkankan fun yin tipatipa. Mo fẹran yin. Mo ni ilana kan ti mo duro le; iyẹn ni Bibeli. A ko lee mu ọrọ kan kuro ninu rẹ. A ko lee fi ọrọ kan kun-un. Mo gba a gbọ bi ą se kọ ọ silẹ.

Ẹ jẹ ki a tẹriba bayi. Oluṣọ-aguntan wa rere, ti o jẹ olootọ, yoo tu ijọ ka. Ki Ọlọrun bukun fun ọ, Arakunrin Neville.

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7